# Ìrora Ìbímọ

Phoenix, Arizona, USA

Osu Kinni, Ọjọ kẹrinlelogun, Ọdun 1965

1 Ẹ jẹ ki a tẹri wa ba. Ọlọrun ọ̀wọ́n, a dupẹ gidigidi loni fun itujade nla Rẹ ti o ti wà ni aarin wa. A n reti eyi ni titayọ, lọpọlọpọ ni ọsan yi. A dupẹ lọwọ Rẹ fun orin ologo yi lati ọdọ arabinrin Kristiẹni ti o sẹ̀sẹ kọ ọrin ati Ẹmi Rẹ ti o sọkalẹ ati ninu itumọ pẹlu. Oluwa, jẹ ki o ri bẹ, a gbadura. Ọlọrun, mo gbadura pe Iwọ yoo bukun ẹni kọọkan ati gbogbo wa ati pe ki ọkan wa kun fun ayọ nigbati a ba ri pe eyi sẹlẹ. Ọlọrun ọwọn, a gbadura ni ọsan yi ti a ba ri diẹ ninu wa nibiyi ti ko mura lati pade Rẹ, jẹ ki eyi jẹ wakati naa ti wọn yoo ṣe ipinnu ikẹhin naa ati pe wọn yoo wa si inu Rẹ nipasẹ ibi tuntun. Ṣe eyi.

Bukun fun gbogbo wa, Oluwa, ti o ti wa ni ojuọna fun igba pípẹ́. A gbadura pe ki Iwọ yoo kọ wa ni awọn nkan titun nipasẹ Ọrọ Rẹ. Fun wa ni oye ti o dara nipasẹ Ẹmi rẹ, Oluwa. Jẹ ki O wa ki O si tumọ Ọrọ naa. Olutumọ kan ti a ni ni Ẹmi. A gbadura pe Oun yoo ṣe èyí fun wa loni. A bèèrè èyí ni orukọ Jesu. Àmín.

[ Ẹnikan jisẹ lati inu àpéjọpọ̀.]

2 Iyẹn titó. Iru àkoko wo! Emi ko mọ ibi ti o dara julọ ti a le wà, bikoṣe ni Ọrun, nitori a ti n ni imọlara itamiororo Rẹ̀ bayi, wo. Ti a joko papọ̀ ninu awọn ọrun ninu Kristi Jesu, ti a péjọ papọ ninu awọn ọrun.

Ki Ọlọrun bukun fun Arabinrin Florence. Ati pe o n la àkókò ibanujẹ ati awọn ojiji kọja - a ṣẹ̀ṣẹ̀ mu baba rẹ lọ, mo gbadura pe, “ki Ọlọrun bukun fun ọmọ naa.”

Ati Arakunrin Demos, ẹrù lori awọn ejika mejeeji, ati gbogbo ẹru awọn apejọpọ wọnyi ati awọn nkan bẹẹ. O nilo awọn adura wa, pelu. Ọlọrun bukun fun Arakunrin Shakarian.

Arakunrin Carl Williams, inu mi dun pe mo wa nibiyi ninu àpéjọpọ̀ yi pẹlu yin ati laarin gbogbo awọn arakunrin daradara wọnyi. Mo ni oore-ofe lati pade diẹ ninu wọn ati pe nibayi eyi ni ìparí ipade naa ti mo n ṣe (bi mo ti ṣe mọ) nitorinaa mo ni ireti bayi pe maa ni anfani lati bọ ọwọ pẹlu diẹ ninu awọn ọkunrin daradara wọnyi ati lati pade wọn; nitori mo nireti lati lo ayérayé pẹ̀lú wọn ni ilẹ ti o dara ju eyi lọ.

3 Nkan kekere kan ni — mo lero pe a ko ni sì mi gbọ́. Ki ṣe pe o sèsì, Emi ko ro bẹ́ẹ̀, tabi mo ro pe a mọ̀ọ́mọ̀ sètò rẹ, lana, a fun mi ni ẹ̀bùn lati ọ̀dọ̀ ọ̀rẹ́ nibiyi — lati ọdọ ọrẹ mi kan, arakunrin Danny Henry. Oun ni ọmọkunrin naa...... Ni ọjọ kan ninu apejọpọ awọn oníṣowo onigbagbọ ni California, mo n ni ipade kan. Mo n sọrọ lile lodi si ipo ti akoko yi, ati pe mo nireti pe gbogbo eniyan lóye rẹ̀ — pe mo ni ibi ninu ọkàn mi. Ki ṣe bẹ. Ẹ loye daju pe emi ko lero lati tumọ rẹ ni ọna yi. Ṣugbọn mo ni lati sọ ohun ti o ba wa si ọkan mi lati sọ.

Lẹhinnaa arakunrin kekere yi, arakunrin ijọ onitẹbọmi kan, mo lero pe o jẹ ibatan si òsèré eré orí-ìtàgé kan. O si sọkalẹ lati fi apa rẹ yi mi ka lati sọ pe, “Oluwa bukun fun ọ, arakunrin Branham. Mo kan fẹ lati gba adura kukuru ni.” O bẹrẹ si ni sọrọ ni èdè Faranse. Ọmọdekunrin naa ko si mọ ọrọ Kankan ni èdè Faranse. Ẹnikan si dìde duro - iru obinrin nla kan lati — mo gbagbọ pe o wa lati Louisiana, o sọ pe, “ èdè Faranse niyẹn.” Ati pe lẹhinna ọkunrin kan wa nibẹ o sọ pe, “ ede Faranse niyẹn!” Wọn si kọ nkan ti o jẹ silẹ. Mo ni ẹ̀dà ojúlówó rẹ̀ nibi. Lẹhinna, o si ṣẹlẹ pé ọ̀dọ́ kan n rin lati ẹhin wa, o si n bọwa si apá iwaju (o fẹ lati rí awọn àkọsílẹ̀ wọn), ati pe o jẹ onitumọ èdè Faranse fun egbé Ìṣọ̀kan Awọn Orílẹ̀-Èdè UN — ede Faranse gangan ni.

4 Emi yoo nifẹ lati ka akọsilẹ yi. Eyi ni akọsilẹ ojúlówó ti ọkan ninu wọn, o si wá lati ọdọ ọkunrin ti o ṣe itumọ yi. Emi lè má lee pe orukọ rẹ ni ọna ti o tọ: Le Deaux, Victor Le Deaux. O jẹ ọmọkunrin Faranse ni kíkún. Bayi, eyi ni isẹ naa:

“Nitoriti iwọ ti yan ọna tóóró naa, ọna ti o nira julọ; iwọ ti rin ni ipa yiyan tirẹ; iwọ ti mu ipinnu ti o jẹ otittọ ati ti o jẹ pipe, o si jẹ ọna Mi. Nitori ipinnu pataki yi, ìpín nla ti ọrun n duro de ọ. Iru Ipinnu ologo wo ni iwọ ti ṣe yi! Eyi ninu ara rẹ ni yoo funni ati pe yoo jẹ ki o wa si imusẹ iṣẹgun nla ninu ifẹ pípé.”

Nigbati mo gba eyi.... Njẹ O mọ, nigbati mo kọkọ gbọ ti awọn eniyan n fi èdè fọ -Emi ko ṣe àtakò si ohun kankan, wo, nitoripe mo ti ri eyiti o jẹ otitọ rẹ, ṣugbọn nigba gbogbo ni mo máa n dáarò. Ṣugbọn nigbati eyi sẹlẹ, ati pe mo ni ìmọ̀ nipa àṣẹ-ifiṣeranni ti o wa lẹhin rẹ, mo mọ pe o wa lati ọdọ Ọlọrun.

5 Nigba naa arakunrin rẹ ti o joko nibi (agbẹjọ́rò ti a mọ daradara) o fun mi ni ẹbun lati ọdọ arakunrin Danny. Danny sẹsẹ kuro ni Ile Mimọ. O dubulẹ lori iboji - ninu iboji dipo, nibiti a tẹ Jesu si lẹhin iku Rẹ. Ati pe nigbati o ṣe eyi, o sọ pe, ohun wa ronú nipa mi. Ẹmi Oluwa si wa si orí mi, o si jade sori oke Kalfari nibiti agbelebu ti waye, o si mu okuta apata kekere kan. Nigbati o pada de, o si ṣe ohun ti a fi ń so ọwọ asọ papọ meji jade ninu rẹ, mo ṣe fẹran wọn gan an ni. Bayi, lẹhin naa, Danny ko mọ eyi, ṣugbọn ni owurọ yi nigbati mo wa ninu adura, Mo kan wo awọn ohun ti a fi nso ọwọ́ asọ papọ yen; ati ọkọọkan wọn, ti o ba ṣe akiyesi, o ni abawọn ẹ̀jẹ ninu ati pe ọkọọkan wọn tun ni ila taara ninu. Ati nibiyi ninu isẹ ti o jẹ lati ọdọ Ọlọrun niti ọna taara ati ọna híhá naa-bi o ṣe jẹ pe o baamu rẹ́gí. Mo ro pe eyi jẹ, boya imọ tẹlẹ Ọlọrun tabi ... ati pe dajudaju

mo dupẹ lọwọ Danny. Ẹ sọ fun ún, arakunrin, bi mo ṣe mọ rírì èyí.

Ati ohun àjèjì miiran, mo beere lọwọ iyawo mi ni owurọ ni ọjọ miiran .... mo wọ asọ ọkunrin ọlọwọ gigun ti o nilo isopọ ni ọrun ọwọ, o si sọ pe, “mo ti gbagbe lati mu awọn ohun ti a fi nso ọrun ọwọ asọ papọ rẹ dani. ”Nitorinaa Oluwa ti pese diẹ fun mi.

6 O, o jẹ igbesi aye ti o ni ògo; sé kii ṣe bẹ́ ẹ̀, arakunrin? Ki a kan rin ninu ìrọrun ti ihinrere, ati sibẹsibẹ ninu ìrọrun rẹ, o jẹ ohun ti o tobi julọ ti Mo mọ. Nko mọ nkan miiran. Ati pe a ṣe é ni irọrun ti o fi jẹ pe mo ni aanfani lati wa sinu rẹ, wo, nípasẹ̀ oore-ọfẹ Ọlọrun.

7 Ni bayi, ni ọsan yi, emi ko nifẹ lati lo akoko pupọ nitori mo mọ pe ẹ nlọ si awọn ile ijọsin yin ni alẹ, ati pe mo ro pe gbogbo awọn alejo ti o wa nibiyi o yẹ ki wọn wo yíká ori pẹpẹ, wo awọn Ojiṣẹ-Ọlọrun wọnyi ati pe inu wọn yoo dun lati ri yin ninu ìsìn wọn ni alẹ́. Wọn yoo ṣe yin daada. Laisi iyemeji ẹ lọ si awọn ile-iwe ẹ̀kọ́ ọjọ isinmi ni owurọ yi ni ilu. Ati pe lakoko ti a n ṣe awọn àgọ́-àjọ wọnyi (ti o si jẹ ti Awọn oniṣowo onihinrere ni kikun) mo ro pe o yẹ ki a fun ún ni gbogbo atilẹyin wa ti a le ṣe si awọn ile ijọsin wa, nitori pe o jẹ ibiti awọn oniṣowo wa n lọ, ati pe o jẹ ilé Ọlọrun. Mo si nireti pe iwọ yoo ṣabẹwo si ile ijọsin kan ni alẹ.

Alẹ ọla ni ipari agọ-ajọ naa, mo gbagbọ, ati pe mo lero pe wọn ti kede ẹni ti yoo sọrọ, eyiti emi yoo wa nibẹ, ti Oluwa ba fẹ́, lati gbọ ìwáásù rẹ̀. Ki Ọlọrun bukun fun ẹni kọọkan ati gbogbo yin.

8 Bayi, emi ko sọ pé mo jẹ oníwàásù, emi ko ni ìmọ̀ ètò ẹ̀kọ́ to lati pe ara mi ni oniwaasu. Oniwaasu, nigbati o ba sọ bẹẹ, wọn nireti pe ó yẹ ki o ni oriṣiriṣi ìwé-ẹri ti ile-ẹkọ giga kọlẹji, ati pe emi ko ni nkankan ṣugbọn kànnàkànnà kekere kan, wo. Mo gbiyanju lati wa lẹhin awọn agutan ti o ṣe aisan ti mo ba le mu wọn pada wa si agbo Baba.

Ti mo ba ṣe awọn aṣiṣe, ẹ dariji mi. Emi ki ṣe onimọ-jinlẹ ti Bibeli. Emi ko ṣe àtakò si awọn onimọ-jinlẹ ti Bibeli; ẹkọ nipa Bibeli. O jẹ ohun ti a nilo. Ṣugbọn nigba miiran mo ṣe atako si ipo ti a ti wa ninu rẹ. Eyi ko tumọ si aládorí ẹni kan. O kan jẹ iṣẹ-iranṣẹ naa. Ki ba wùn mi pe kii ṣe emi ni ma jiṣẹ. O ma n jẹ ki ṣe àárẹ̀ nitoripe mo mọ bi o ṣe ti ri lara.

Bawo ni ti awọn ọmọ yin, wo, ṣe ko jẹ ìnira fun yin lati fun ọmọ ni ibawi, ki wọn maa sunkún sita, tabi nkankan bi o tilẹ jẹ pe? Mo jẹ obi, paapaa, ati pe mo mọ ohun ti eyi tumọ si. Mo si ni igbagbọ pe ẹ o dariji mi.

9 Ati pe mo fẹ ki iwọ ṣe bi eyi: nigbati o ba joko ni ọsan yi emi yoo bèèrè ojú-rere lọwọ rẹ. Mo ni awọn ìwé-akọsilẹ kekere diẹ nibi. Gẹgẹ bi mo ti sọ fun yin, mo ni lati ṣe ... kọ awọn iwe-mimọ mi jade. O maa n jẹ tẹlẹ pe mo le fẹrẹ sọ awọn ayọka Bibeli lati orì lai ma wo Bibeli, ṣugbọn ki ṣe bẹẹ mọ bayi. Mo ti la ọpọlọpọ awọn ogun lile kọja; mo ti dagba ju fun eyi. Ṣugbọn mo ni igbẹkẹle pe iwọ yoo tẹti si mi fun igba diẹ ni ọsan yi, ki o kan si ọkan rẹ gan an ki o si gbiyanju lati ni oye ohun ti mo n sọ. Lẹhinna mo ro pe yoo dara, paapaa julọ awọn oluso-aguntan ti ilu ati oriṣiriṣi awọn agbegbe miiran. Mo ni igbẹkẹle pe iwọ yoo tẹ̀tì si i gidigidi.

Bayii ki iwọ ṣe ni ọna ti mo fi maa n ṣe nigbati mo ba n jẹ àkàrà oníyẹ̀fun mi ti mo fẹran, èso sẹ́ẹ̀rì; diẹ ninu ẹran ti mo fẹran, adiyẹ. Nigbati mo ba n jẹ lara akara oniyẹfun ti o dara ti a fi eso sẹẹri ṣe ati pe ti mo ba kan irugbin koro kan, Emi kò ni da akara oniyẹfun naa duro; mo kan maa yọ kóró irugbin naa jade, maa si tẹsiwaju lati maa jẹ akara oniyẹfun. Nigbati mo ba kan egungun ninu adiyẹ kan, emi ko ni ju adiyẹ naa sílẹ̀; maa kan ju egungun naa dànù. Nitorinaa, ti mo ba sọ nkan ti iwọ ko gbagbọ ninu rẹ nigbakugba, iwọ kan ju apakan yẹn dànù, ṣugbọn ki iwo kó wo daada gidigidi; ri daju pe o jẹ egungun bayi! Lẹhinna jẹ ki emi tun sọ pé, ti o bá jẹ́ koro irugbin, ranti, yoo mu igbesi aye tuntun jade. Nitorinaa wo gidigidi, ki Oluwa ko bukun yin.

10 Arakunrin Carl Williams sọ nkan ni alẹ ọjọ kan nipa fifi àyè silẹ lati gbadura fun awọn alaisan, eyiti yoo dara pupọ. Mo mọ pe eyi yoo dara. Ṣugbọn a ni lati ...... a ko wa si ibi fun eyi: lati mu ila adura wa. Emi ko si mọ boya Arakunrin Oral tabi eyikeyi ninu awọn arakunrin miiran ti ni ila adura ninu awọn agọ-ajọ tabi rara. Nkò mọ. Mo ti gbiyanju rẹ ni igba meji tabi mẹta, ṣugbọn ni irufẹ igba ti eniyan ba pọ bi eyi iwọ yoo nilo lati pín awọn kaadi adura, wo, lati le ṣe eyi, 'nitori iwọ ko le ṣe eé.... Kii ṣe ibi-ìgbafẹ́; ile Ọlọrun ni, wo, a pinlẹ̀ ṣe eé fun eyi ni. Ati pe wọn yoo ma ti ara wọn ati kíkọlu ara, ṣugbọn, ti o ba ni awọn kaadi, iwọ yoo tò wọn si ori ila ni lọ́wọ̀ọ̀wọ́.

Nitorinaa ọmọ mi Billy beere lọwọ mi, o sọ pe, “Ṣe ki emi ki o lọ ki n si pín awọn kaadi jade? Awọn eniyan n beere lọwọ mi fun awọn kaadi adura.”

Mo sọ pe, “Rara, Billy. Jẹ ki a kan fi silẹ fun Ẹmi Mimọ ki O ṣe ohun ti O fẹ lati ṣe.” Wo, jẹ ki Oun boya O lè fẹ́ ru igbagbọ soke, ki o kan gba iwosan ni àrọ́wọ́tó ni ibiti o wa. Wo?

Ṣugbọn awọn.... Wo, iwosan lati òkè wa jẹ kekere ninu ihinrere, ati pe o ko le pe ohun kekere ni nla laelae.

Ko si ẹniti ko mọ eyi. Ṣugbọn o jẹ ẹtan ti a lo lati jẹ ki awọn eniyan gbagbọ ninu wíwà laaye agbara ti o ju ti ẹda lọ, tabi Ọlọrun, ti o jẹ Agbara lati ọrun wà nibi. Ati pe lẹhinna, ti wọn ba le ṣe ìdánimọ̀ wiwa laaye Rẹ, lẹhinna wọn yoo gba imularada, wo, nipa igbagbọ ti wọn ba gba eyi gbọ.

11 Ni bayi, mo fẹ ka diẹ ninu Ọrọ Ọlọrun, Majẹmu Titun, ati lẹhinna mo fẹ lati mu àkòrí lati inu Majẹmu Titun yi ati Iwe-Mimọ yi ki a si sọrọ ni ọsan yi lori kókó àkòrí fun ìgbà diẹ. Emi ko nifẹ lati gba yin láàkókò pupọ fun awọn isin ni alẹ yi, ṣugbọn ranti, mo nireti pe mo ti ṣe àlàyé ara mi, ẹ kan fun ni ìtẹtisilẹ rẹ fun igba diẹ, ti ẹ ba le ṣe bẹẹ.

Ni bayi ki a to ṣe eyi, jẹ ki a tẹ orí wa ba lẹẹkansi. Ṣe o mọ, a le kọrin pupọ ju. A le kigbe pupọ ju titi di igba ti ohùn wa yoo fi há. Ati pe a le kọrin ni àkokò ti ko tọ́ tabi kigbe ni àkokò ti ko tọ́, ṣugbọn ohun kan niyi, a ko kúrò ni ilana eto rara nigbati a ba n gbadura. "Emi yoo fẹ ki awọn ọkunrin máa gbadura nibi gbogbo ki wọn máa gbe ọwọ́ mimọ soke laisi iyemeji tabi..."

12 Baba, o jẹ oore-ọfẹ nla julọ ti eniyan ẹlẹran ara le ni lati pa oju rẹ de ki o si ọkan rẹ ki o ba Ọ sọrọ. A mọ pe O gbọ ti a ba le gbagbọ pe O ti gbọ, nitori Jesu sọ pe, "Ti o ba beere ohunkohun lọwọ Baba ni orukọ Mi iwọ yoo ri gba." Iyẹn wa lori kááni pe ti a ko ba siyemeji. Nitorinaa Baba, ran wa lọwọ lati gbagbọ ni ọsan yi pe awọn ẹ̀bẹ̀-adura wa yoo gbà, ati pe boya ko ni si iyèméjì kankan nibikibi, ṣugbọn jẹ ki o wa si ìmúṣẹ awọn ohun ti a n bèèrè.

Ati Oun ni Ọlọrun, fun orukọ nla Rẹ ni ọla loni nipa mímúwá si ijọba Rẹ gbogbo ọkàn ti o ti sọnu ati ti o ti sáko ti o n gbọ ohùn wa; tabi ohùn ti a ti ká sínú ẹrọ yi yoo de ọdọ wọn, jade lọ si awọn ilẹ keferi nibiti wọn ti lọ kakiri agbaye.

Mo gbadura, Baba ọrun, pe ko ni si alaisan Kankan larin wa loni. Nigbati isin ba pari, ki Oluwa Ọlọrun gba gbogbo ọkàn ti o ti sọnu là ati ki o ṣe imularada fun gbogbo awọn alaisan, ki o fi ayọ̀ kun ọkan awọn ọmọ Rẹ. Ìdí niyi ti a fi ni igbagbọ, Oluwa, lati beere ni orukọ Jesu si Ọlọrun Baba wa: nitori pe O ṣe ileri pe Oun yoo gbọ́, ati pe eyi jẹ fun ogo Rẹ. Àmín.

13 Ninu Iwe Ihinrere ti Johanu, ori kẹtadinlogun bẹ̀rẹ̀ lati ẹsẹ̀ ogun, mo fẹ lati ka fun àkòrí kan. Mo ro pe eyi tọ́.

*Ki si íṣe kìkì awọn wọnyi ni mo n gbadura fun, ṣugbọn fun awọn pẹlu ti yoo gba mi gbọ nipa ọrọ*

wọn ;

*Ki....*

Mo gbagbọ pe mo ti ṣi ibití o kuna. Bayi, mo tọrọ gáfárà fun iṣẹju kan. Mo n wa ibití adura Jesu wa pe ... tabi, ki ṣe adura Jesu, ṣugbọn fun awọn tiRẹ.... Mo le ti sámí si tẹ̀lẹ́ nibiyi lori àkòrí mi nkankan ti kùnà. Nibiti Jesu ti gbadura pe ... tabi, n sọ pe " gẹgẹ bi obinrin ti ṣe wa ninu ìrora fun ìbí ọmọ rẹ" - ìbí, ibimọ. Ṣe kìí ṣe ìwé Luku tabi Johanu? Arakunrin Jack, ninu íbo ni èyí wà? Ẹsẹ kẹrindilogun iwe ihinrere ti Johanu. Mo ro pe eyi tọ́, ṣugbọn ko dun pupọ bi ẹnipé ohun ni. Ẹsẹ kẹrindilogun iwe ihinrere ti Johanu [Ọkunrin kan lati ori pẹpẹ sọ pe, "ẹsẹ̀ óòkan le lógún."], ẹsẹ̀ óòkan le lógún. Dajudaju. Ẹsẹ-óòkan le logun. Dajudaju, nibiyi lo wa. Iwe ihinrere ti Johanu orí kẹrindinlogun ati ẹsẹ̀ óòkan le logun:

*Ki wọn le jẹ....*

14 Rara, Arakunrin Jack, eyi si tun jẹ aṣiṣe. Mẹrindilogun ati ookan-le-logun. Mo mọ ori kẹrindinlogun iwe ihinrere ti Johanu, ẹsẹ̀ ookan-le-logun, ṣugbọn emi ṣe aṣiṣe! O dara, aṣiṣe wa ninu Bibeli yi. Bẹẹni, sa. Wọn ṣe aṣiṣe nigbati wọn n tẹ̀ ẹ́ jade. Bẹẹni, sa. Ṣe o mọ nkan? Eyi ni otitọ gangan. Eyi ni Bibeli tuntun; Mo sẹsẹ gba àá ni, ati pe o ni...

wọn ṣe aṣiṣe nigbati wọn n tẹ̀ ẹ́. [Alufaa ijọ àgùdà kan gun ori oke àga iwaasu, o fun Arakunrin Branham ni Bibeli rẹ o si sọ pe, "Eyi ṣẹlẹ nibi. Idi kan wa ti o fi ṣẹlẹ, ati pe Ọlọrun yoo fihan fun ọ, lati mu Iyanu Rẹ jade ninu rẹ (ọ̀rọ̀ ti a ko gbọ dáadáa)." ]

O dara. A dupẹ. Ẹ ṣeun pupọ. Mẹrindilogun, ookanlelogun. Ẹ ṣeun pupọ. Ooto ni o je.

*Obinrin nigbati o....*

*Lootọ, lootọ ni mo wi fun nyin, pe, Ẹnyin o maa sọkun ẹ o si maa pohúnrere ẹkun, ṣugbọn awọn araye yio ma yọ̀: inu nyin yio si bajẹ ...ṣugbọn ibinujẹ nyin li yio si di ayọ̀.*

*Nigbati obinrin ba nrọbi, a ni ibinujẹ, nitoriti wakati rẹ̀ de: ṣugbọn nigbati o ba ti bi ọmọ na*

*tan, on ki si iranti mọ́ ... irora, fun ayọ nitori a bi eniyan si aye.*

Mo dupẹ pupọ lọwọ yin, arakunrin mi. Mo mọ rírì rẹ̀ daju. Bayi, ni tootọ aṣiṣe wa nibi ninu Bibeli yi ... a ṣe aṣiṣe ninu oju-iwe ti a fi sinu, ati pe mo kan ri i lori Bibeli Scofield mi atijọ pe mo si mu eyi, mo si sáré wa si ihin pẹlu rẹ ni iṣeju diẹ sẹhin ('nitoripe iyawo mi ṣẹṣẹ fun mi ni eyi fun ẹbun ọdun Keresimesi).

15 Ni bayi, mo fẹ lati sọrọ ni ọsan yi lori àkòrí kan ti mo ti kede: "Ìrora Ìbímọ." Bayi o dabi pe ko dun un gbọ létí, ṣugbọn o wa ninu Bibeli. Mo gbagbọ pe Jesu n sọrọ nipa rẹ nibiyi, bi O ti sọ, "Iwọ yoo ni ibanujẹ, ṣugbọn ibanujẹ rẹ yoo di ayọ" - O n sọrọ nipa awọn ọmọ-ẹhin Rẹ nibi, bi O ti ṣe mọ pe a o bí ẹsin Kristiẹni laipẹ.

Bayi, ògbólógbò naa ni lati ku ki ànfàní le wa lati bi tuntun. Lati ni.... Ohunkohun ti o ba n bi ọmọ ni lati ni irora ti ìnira, ati pe dajudaju wọn ni lati la irora ti ìnira ati ipọnju kọja ki wọn le rekọja lati inu òfin sinu ore-ọfẹ.

Ìbí ti o jẹ pípé ati ti o si jẹ lai ṣe iṣẹ abẹ n ṣe apẹẹrẹ iru ìbí ti ẹ̀mí. Gbogbo ohun ti o jẹ ti ẹ̀dá - ti ara n ṣe apẹẹrẹ ti ẹmi. Ati pe ti a ba ṣe akiyesi ti a ba wo ilẹ ti a si ri igi kan ti o n dagba lori ilẹ, o n tiraka lati ni iye. Eyi lo fi han fun wa pe igi kan wa nibikan ti ko ni ku, nitoripe o n kérora fun ohun kan. A ri awọn eniyan, bi o ti wu ki wọn dagba to, bi wọn ti le ṣe aisan to, ipo-ki-po ti wọn wa wọn n kerora lati wa laaye nitori èyí fi han fun wa pe ìyè kan wa nibikan nibiti a o gbé — gbé laelae. Ṣe akiyesi bi o ṣe jẹ pipe.

16 Ni bayi, ninu iwe Johanu kinni ori karun un ẹsẹ keje 1 Johanu 5:7 (Mo gbagbọ pe ohun ni, ti n ko ba ṣe aṣiṣe), o sọ pe, "Awọn mẹta ni o njẹri ni ọrun: Baba, Ọrọ, ati Ẹmi Mimọ: awọn mẹtẹta yi si jẹ ọkan. Awọn mẹta ni o njẹri ni ayé; eyi ni omi, ẹ̀jẹ, ati Ẹmi, ati pe awọn mẹtẹta si fi ohun sọkan." Bayi, awọn mẹtẹta àkọ́kọ́ jẹ ọ̀kan; awọn mẹtẹta keji jẹ ti ayé wọn si fi ohun sọkan. O ko le ni Baba laisi Ọmọ; o ko le ni Ọmọ lai ni Ẹmi Mimọ. Ṣugbọn o le ni omi laisi ẹjẹ ati ẹjẹ laisi Ẹmi.

Mo ro pe nipasẹ awọn igba ijọ wa a ti fi ìdí eyi mulẹ pe o jẹ otitọ. Omi, ẹjẹ, Ẹmi; idalare, isọdimimọ, Iribọmi ti Ẹmi Mimọ. Eyi n ṣe àfiwé tabi imusẹ rẹ eyiti a mu jade lati inu ìbí ti ẹda. Wo nigbati obinrin kan tabi ohunkohun ba wa ninu ìrora ti ibimọ, ohun àkọkọ yoo sẹlẹ̀: omi a tú jade (ibimọ ti ko ni isẹ́ abẹ ninu); ohun keji ni ẹjẹ; ati lẹhinna ni ìyè; omi, ẹjẹ, ẹ̀mi. Ati pe eyi jẹ àpapọ̀ ibimọ pípé, ibimọ ti ko ni iṣẹ́ abẹ nínú.

17 Bẹẹ si ni o ṣe wa ninu ìpele ti ẹmi. Omi ni; idalare nipa igbagbọ, gbigbagbọ ninu Ọlọrun, gbigba A gbọ gẹgẹ bi Olugbala rẹ kan ṣoṣo, ati ki o ṣe iribọmi. Ikeji jẹ isọdimimọ ti Ẹmi, pe Ọlọrun ti wẹ ẹ̀mí mọ kuro ninu gbogbo awọn ohun ti aye ati ifẹ ti aye. Lẹhinna, Ẹmi Mimọ wa wọle O si fun ọ ni ìbí tuntun ati pe o si kun ohun èlò naa ti a sọ di mimọ.

Fun apẹẹrẹ bi eyi; bayi pe... Ti mo ba sọ ohun ti iwọ ko gbagbọ fun ọ yọ ọ kuro ati lẹhinna jẹ akara oniyẹfun naa. Ṣe akiyesi. Bayi, ìgò kan wa nilẹ lori ààtàn lágbàlá. Iwọ ko kan ni gbe eyi ki o fi si ori tabili rẹ ki o si rọ omi si tabi wara. Rara. Nipa mimu un kuro nilẹ jẹ idalare. Fífọ̀ ọ́ jẹ isọdimimọ, 'nitori ọrọ Giriki sọ-di-mimọ jẹ ọrọ ti a so papọ, o tumọ si sọọ di mimọ ki o si yaasọtọ fun lilo (kii ṣe pe o loo lọwọ; fun lilo). Lẹhinna nigbati o ba kún un, o ti fi sinu isẹ.

18 Ẹ gba mi laaye fun eyi (kii ṣe lati ṣe ipalara), nibiyi ni ẹyin ijọ atipo mimọ - Pilgrim Holiness, ẹyin ijọ Nasareti - Nazarenes kuna lati rin lọ sinu Pẹntikọsti. A fọ yin mọ nipasẹ isọdimimọ, ṣugbọn nigbati o yẹ ki a yin sinu isẹ nipasẹ awọn ẹbun fifi ede miiran sọrọ ati awọn ohun miiran, ẹ kọ ọ silẹ, ẹ tun pada sinu àbàtà lẹẹkansi, wo. Bayi eyi ni ohun ti o sẹlẹ; nigba gbogbo ni eyi si maa ń ṣẹlẹ. Bayi, ki ṣe lati ṣe àtakò rẹ bayi, ṣugbọn mo kan ... mo fẹ lati gbe eyi kuro ni ọkan mi. Ati pe eyi si ti n gbóná ninu mi lati igba ti mo ti wa nibiyi nitorina jẹ ki n ṣe eyi ….... Bi oore-ọfẹ arakunrin Carl ati ti arakunrin Demos ati awọn ati gbogbo yin.... maa gbiyanju gbogbo ipa mi lati gba ẹmi mi lọwọ rẹ, wo; lẹhinna o wa ku si ọ lọwọ.

Ti ara n ṣe afiwe ti ẹmi. Bayi, a ri i.... Lẹhinna a bi i ni kikun. Nigbati ọmọ naa.... Bayi bi o ṣe maa n ri nigba gbogbo nigbati omi ba jade, o ko nilo lati ṣe wahala pupọ nipa rẹ. Nigbati ẹjẹ ba jade, o ko nilo lati ṣe wahala pupọ nipa rẹ. Ṣugbọn lati le jẹ ki iye wa sinu ọmọ naa, o ni lati fun ni ìláàdí kan ti yoo jẹ ki o kigbe jade. Ati eyi..... ni bayi lai ka iwe - kika, bi awọn arakunrin mi ti o wa nibiyi ti wọn ti gba eto-ẹkọ daradara nipa rẹ (ti awọn), ṣugbọn mo ni lati lo isẹ́ ti ẹ̀dá lati fi ṣe afiwe rẹ. Ati pe ṣe o rii. Eyi ni ohun ti o sẹlẹ; o gba fifun ni ìláàdí gidigidi lati le jẹ ki wọn rii.

19 Ni bayi mu diẹ ......gbígbọ̀n diẹ kan. Boya o ko nilo lati fun u ni ilaadi, ṣugbọn o le jẹ pe ki o kan fun ni gbón diẹ. Nipa wipe a bii nigba miiran yoo ṣe. Di i mu; gbọn ọn. Ti ko ba ti si èémí ninu rẹ, fun u ni ilaadi diẹ, lẹhinna yoo kigbe jade pẹlu ede aimọ (si ara rẹ mo ro bẹẹ). Lọnakọna ti o jẹ o n kigbe. Mo si ro pe ti a ba bi ọmọ kan nipaṣe oku-ọmọ ti ko si kigbe ti ko sí ohùn, ko si imọlara; iyẹn jẹ pe ọmọ naa ti ku.

Eyi ni ohun ti o n sẹlẹ pẹlu ijọ loni, ilana eto wọn — a ti ni ọpọlọpọ awọn oku-ọmọ ti a bi. Eyi jẹ otitọ. Wọn nilo ilaadi ti ihinrere, ṣe o ri, ati bẹbẹ lọ ... lati ji wọn dide, lati jẹ ki wọn ni ìdánimọ̀ ara wọn ki Ọlọrun le mi eemi iye sinu wọn! Bayi a ri pe eyi jẹ otitọ. O jẹ ẹkọ-ijinlẹ ti o múnádóko, ṣugbọn o jẹ otitọ lọnakona.

20 Kiyesi bayi ninu ibimọ ti irugbin, irugbin atijọ gbọdọ ku saaju ki a to le bi irugbin tuntun. Nitorinaa, iku jẹ ohun ti o nira nigbakugba. Nitori, o maa dunni lọpọlọpọ, o jẹ ohun ibanujẹ. Ibimọ jẹ bakanna; nitori pe o n mu iye wa si aye, ati pe o ni irora.

Jesu sọ pe Ọrọ Rẹ jẹ irugbin ti afunrugbin kan jade lọ lati gbìn. (Bayi gbogbo wa la mọ eyi pẹlu, ati pe mo fẹ lati kọ́ eyi bi ẹkọ ile-iwe Ọjọ-Isimi 'nitori o jẹ Ọjọ Isimi.) Ṣe akiyesi, lẹhin Ọrọ naa, ti o jẹ irugbin.... Ṣugbọn ranti, irugbin naa n mu ìyè tuntun jade nikan nigbati o ba ku. Idi si niyi ti o fi nira fun awọn Farisi wọnyẹn lati ni oye Jesu Kristi Oluwa wa: nitoripe wọn wa labẹ ofin. Ati pe ofin jẹ Ọrọ Ọlọrun ni ìrí ti irugbin. Ṣugbọn nigbati a sọ ọrọ naa di ara ati pe ti o si di oore-ọfẹ, yatọ si ofin. Ni bayi, oore-ọfẹ ati ofin ko le wà papọ ni akoko kanna, 'nitori oore-ọfẹ ga ju ofin lọ ni ọna giga, ofin paapaa ko si ninu aworan naa. Nitorinaa, o nira pupọ fun awọn Farisi lati kú si ofin wọn ki a le bí oore-ọfẹ. Ṣugbọn o gbọdọ lọ. Awọn ofin mejeeji ko le wà papọ ni akoko kanna.

Ko le si ofin kan ti o sọ pe o le fi sare kọja ni ọna yi, ki ekeji si sọ pe o ko le fi ṣe bẹẹ. Ọkan sọ pe o lee ṣe; ekeji sọ pe o ko lee ṣe. O ni lati jẹ ofin kan ni akoko kan. Boya ni akoko kan o le ti lọ ninu rẹ; ìjánu, lọ ninu rẹ. Ṣugbọn ni akoko yi àwọ̀ pupa ni, duro! Wo? Nitorinaa awọn ofin mejeeji ko le wa papọ ni akoko kanna.

21 Bayi, a ṣe akiyesi pe nigbagbogbo. Ero mi bayi si yin ni pe o gba irora, ipọnju, inira. Wo bi awọn Farisi ṣe ku si ofin yẹn, nipasẹ irora, ipọnju, inira. Ṣugbọn o gbọdọ jẹ bẹ ẹ.

Bayi a ri ójó ti o mu eso jade wa sori ilẹ, “A bi i,” gẹgẹ bi akewi naa ti ṣe sọ, “ni ori-pàpà ti àrá, ni oju-ọrun ti o ri pálapàla.” Ṣugbọn ti a ko ba ni àrá ati awọn oju-ọrun ti o ri palapala, ìkán omi-òjò kekere naa ti a gbe lati inu okun ati ti a sọ di mimọ lati inu iyọ, a ko ni bi i. Yoo gba mọ̀nàmọ́ná, àrá, awọn ariwo, palapala, gaungaun, ohun ti o ni ibẹru lati mu awọn omi kekeke jade. Yoo gba irora lati mu ìbí jade; o gba kiku. Ati bi awọsanma ti n ku, a mu ojo jade; nitori ojo jẹ apakan ti awọsanma. Ikan ni lati duro ki ekeji le waye. Ni bayi bi awọn arakunrin mi nibiyi (diẹ ninu wọn) ba ni anfani, wọn le fun ọ ni gbogbo ofin awọn nkan wọnyi. Nko le ṣe e.

22 Ṣugbọn nisisiyi jẹ ki a tun sọ nkan miiran fun ẹri kekere kan. Mo ro pe ọkan ninu awọn ododo ti o dara julọ……....

Onikaluku eniyan ni o ni èrò ti ara rẹ nipa wọn. Ṣugbọn mo ro pe ododo ti o dara julọ ti o dabi ẹnipe mo ti fẹrẹ ri tẹlẹ ni (ni apá Ila-oorun) òdòdó lílì wa ti o wa ni ibi omi. Melo ninu wa ni o ti ri ododo lili ti o wa ni ibi omi ri? Akika, ko si nkankan ti o dabi rẹ si mi. Ṣugbọn ṣe o ṣe akiyesi ohun ti ododo lili ti o wa ni ibi omi yii yoo jẹ. Mo ronu nipa ohun ti Jesu sọ: “Ṣe akiyesi lili, bi o ṣe n lakaka ati bi o ṣe n fún ara rẹ pa, ṣugbọn sibẹ mo sọ fun yin pe Solomoni ninu gbogbo ogo rẹ, a ko wọ ọ ni asọ bi ọkan ninu awọn wọnyi.” Nitori fun ogo Solomoni ati gbogbo iwọsọ rẹ jẹ ti àtọwọ́dà, ṣugbọn lili ninu ẹwa rẹ ni ìyè ti o ń jẹ ki o lẹwa, kii ṣe awọn ohun elo atọwọda ti o dọti, ti a ti kùn-lọda.

Gẹgẹ bi awọn obinrin wa. Emi ko ro pe o ni lati ni gbogbo awọn ọda alawọ ewe yi, ṣe o mọ, ati awọn ohun ti a di mọ oju ti o jẹ ki oju maa sẹju, o mọ iru bẹ, ati gbogbo eekanna naa, tabi rara.... Mo ṣe aṣiṣe nkan naa ... gbogbo rẹ loju rẹ lati le jẹ ki o lẹwa. Ẹwa gẹgẹ bi ẹwa ti maa n ṣe. Ti o ba mu iwe Iṣe awọn Aposteli ori keji 2 ati ẹkẹrin 4, ki o si po gbogbo rẹ papọ pẹlu iwe ti Johannu kekere kan ori kẹta ẹsẹ kẹrin-din-logun (Johannu 3:16), yoo tayọ ju ohunkohun ti ohun ikunju n gbiyanju lati ṣe fun ọ lọ. Ọkọ rẹ yoo nifẹ rẹ sii, gbogbo awọn eniyan yoo nifẹ rẹ, ati pe mo ni idaniloju pe Ọlọrun yoo nifẹ rẹ pẹlu.

23 “Lili”, O sọ pe ki a roo wo, bi o ṣe n dagba, tiraka, lati mu ara rẹ dagba. Ododo lili kekere yii ti o wa nibi omi, wo lati ipasẹ ibiti o ti wa: idọti, ẹ̀gbin, pẹtẹpẹtẹ, omi ẹrẹ̀, omi idọti; o maa ti ara rẹ la gbogbo eyi kọja (iru ìyé kekere yii) ti o n la ọna ara rẹ lati isalẹ adagun omi nibiti awọn ọpọlọ ati awọn nkan bayi wà, ti o si tun mu ara rẹ goke wa laarin gbogbo nkan wọnyi. Ṣugbọn nigbati o ba dé iwaju oorun, a bi i. Irugbin kekere naa bu jade sinu iye. Ko si le ṣe eyi, ayafi ti o ba kọkọ kọja ninu gbogbo ilana naa. O ni lati la gbogbo ilana wọnyi kọja, eyi ni o jẹ ki o ri bẹ, nitori pe oorun funrararẹ ni ohun ti o n faa. Ati pe nigbati o ba ti goke gbogbo omi idọti yii ni kikun ati ẹgbin ati bẹbẹ lọ, lẹhinna inu rẹ yoo dun pupọ yoo kan fi iye rẹ jade fun ni ni ọfẹ. Ati pe o jẹ igbesi aye ti o dara nigbati o ba wa niwaju ohun naa ti o n fa a.

Mo ro pe eyi jẹ apẹẹrẹ iru igbesi aye Onigbagbọ ti o dara. Nigbati ohun kan ba n fa ọ jade kuro ninu aye titi di ọjọ kan ti a bi ọ sinu iwaju rẹ nipasẹ Ẹmi Mimọ. Bi o ṣe lẹwa to! Ti o ba gbiyanju lati ran an lọwọ, iwọ yoo pa a.

24 Bi adiye kekere kan nigbati a ba n bi i. Ṣe o mọ, Njẹ o ti ṣe akiyesi ọkan ninu awọn adiyẹ kekere wọnyi? Ni ibi oke ẹnu rẹ (tabi eyikeyi ẹyẹ ti a bi lati inu ẹyin) o ni lati...... O maa n pèsè èpo-ẹyin atijọ. Inu-ẹyin ti atijọ naa ni lati rà danu. Ati pe yoo mu ẹnu kekere yi lati fi há sẹ́yìn ati siwaju titi yoo fi fọ́ epo-ẹyin naa jade. A pe ni “fífọ́ ọna rẹ jade” ni ilu Kentucky lọhun nibiti mo ti wa. Fífọ́ ọna rẹ jade. Wọn ko ti ri ọna ti o dara julọ miiran. Kini idi? O jẹ ọna ti Ọlọrun ti pese. Ti o ba gbiyanju lati ran an lọwọ, iwọ yoo pa a. Mu epo-ẹyin kuro lọdọ rẹ, yoo ku. Wo, o ni lati làkàkà, ni inira, fọ jade!

Eyi ni ọna ti Kristẹni ni lati tọ̀. Ki ṣe pe ẹnikan yoo kan bọ ọwọ rẹ, ki a mu ọ wọle. O ni lati duro nibẹ titi iwọ yoo fi ku, ki o, ki si a bi ọ sinu ijọba Ọlọrun. Eyi ni ọna ti Ọlọrun ti pese. O ko le wọle sinu rẹ nipasẹ iwe, tabi bọ ọwọ ki o si darapọ mọ wọn, bẹ soke, bẹ si salẹ. O ni lati kuro ninu èpo-ẹyin naa. Sẹ akiyesi, ko ti si ọna miiran ti o dara julọ ti wọn ti i ri.

25 Wọn ko ti ri ọna miiran ti o dara julọ fun ọmọ lati gba ohun ti o n fẹ yatọ si ilana ti Ọlọrun ti pese. Ni bayi, nigbati a ba bi ọmọ kekere kan, o le ṣeto agogo kan silẹ nibi ẹgbẹ ibùsùn ọmọ kekere yii. Ki o sọ pe, "Ọmọkunrin mi kekere, mo jẹ onimọ-jinlẹ ni ojuọna yi.... Mo ti ka awọn iwe lori bi a ṣe n tọ ọmọ dagba, ati pe mo sọ fun ọ, ọmọ igbalode ni ọ. A bi ọ ni ile igbalode lati ọwọ awọn obi ode oni. Nigbati ebi ba n pa ọ tabi o nilo iya tabi emi, iwọ saa lu agogo kekere yi. "Eyi ko le sisẹ laelae. Ọna kan soso ti o le gba lati gba ohun ti o fẹ ni lati sọkún fun. Eyi ni ọna Ọlọrun.

Ati pe ọna yi ni ọna ti a le gba lati gba ohun ti a fẹ a ni lati sọkun fun! Kigbe sita! Maṣe jẹ ki oju ko ti ọ. Sọ pe, "Mo n pòǹgbẹ fun Ọlọrun!" Maṣe bikita boya awọn diakoni, awọn oluso-aguntan, tabi ohunkohun ti ki i ba jẹ, wa ni ayika. Pariwo sita lọnakọna! Ti awọn ogbẹni Joneses ba joko nibẹ, iyatọ wo ni eyi jẹ? Kigbe soke! Eyi nikan ni ọna ti o wa ti iwọ yoo fi gba aa — titi iwọ yoo fi ri iranlọwọ. O kọ èyí nigbati O wa si aye, ṣe o mọ, nipa adajọ alaiṣododo.

26 Ìkán ìrì diẹ — Emi ko mọ ẹkọ-aropọ rẹ. Boya onimọ-jinlẹ kan wa nibi, ṣugbọn emi yoo sọ ni ọna ti mo ro. O le jẹ iru akojọpọ ikuuku kan ti o korajọ papọ ni òru dudu, O si rọ̀ si ori-ilẹ. Nigbati o ba si ṣe eyi, a bi ni alẹ. Ṣugbọn ni owurọ, o wa nibẹ o tutù ati pe o n gbọ̀n lori ibi abẹfẹlẹ koríko kekere kan tabi ti o so rọ̀ lori ila-asọ rẹ. Ṣugbọn jẹ ki oorun kan tàn jade lẹẹkan. Njẹ o ṣe akiyesi bi o ṣe dun to? O kan maa n dan ati pe a maa bì. Kini idi? O mọ pe oorun yi ni yoo fa ohun pada lọ si ibiti ohun wa ni ibẹẹrẹ.

Bẹẹ gẹgẹ ni gbogbo onikaluku ọkunrin tabi obinrin ti a bi nipa ti Ẹmi Ọlọrun. Nkankan wa nipa rẹ nigbati ina ba tan yika sori wa, inu wa yoo dun nitoripe a mọ pe a n pada lọ si ibiti a ti wá, lati inu óokán-àyà Ọlọrun. O le tan pẹlu ayọ nigbati oorun ba tàn si i, dajudaju, o mọ pe oun nlọ si ibiti oun ti wa. Awọn ohun kekere ti ìsẹ̀dá, titi ni a o fi maa tẹsiwaju pẹlu rẹ. Ṣugbọn jẹ ki a wa nkan miiran.

27 A mọ pe irugbin ògbó gbọdọ, saaju ki irugbin titun to le jade kuro lati inu irugbin ti tẹlẹ, o gbọdọ jẹrà. Ni dajudaju. Kii ṣe kó kú nikan, ṣugbọn ko jẹra lẹhin ti o ti ku. A mọ pe eyi jẹ otitọ. Bakanna ni o jẹ ninu ibi tuntun. A ko pada sẹhin, ṣugbọn a n lọ siwaju, nigbati o ba di atunbi.

Idi niyi ti mo fi ro loni pe a ni ọpọlọpọ ... ki ṣe ọpọlọpọ, ṣugbọn, ojúlówó ibi tuntun, o jẹ pe nitori irugbin yi jẹ....Boya yoo kaanu pẹlu Ọrọ naa tabi eniyan naa, ṣugbọn wọn ko fẹ lati jẹrà kuro ninu eto atijọ ti wọn ti wa. Wọn ko fẹ jade kuro ninu rẹ. Wọn fẹ lati duro ninu eto atijọ ki wọn si maa jẹ́wọ́ ibi tuntun tabi isẹ-iransẹ ti akoko naa.

A ri eyi labẹ igba ojisẹ Ọlọrun Luther, ojisẹ Ọlọrun Wesley, igba Pentikọsi, ati gbogbo awọn igba-ijọ miiran. Wọn si tun gbiyanju lati rọ̀mọ́ eto atijọ ati ki wọn jẹwọ eyi, ṣugbọn eto igba atijọ gbọdọ ku, ki o jẹra, ki anfani le wa lati mu tuntun jade. Wọn si tun fẹ lati rọmọ.

28 Ṣe akiyesi, wọn mọ pe eto atijọ ti ku, ṣugbọn wọn ko fẹ lati jẹra jade kuro ninu rẹ. Bayi, jẹra tunmọ si nigbati o ba kuro ninu rẹ patapata.

Nigbati a ba jẹwọ pe wọn di atunbi, Ṣugbọn ijẹwọ kàn jẹ ami ìbí; jijẹra jẹ mimu ìbí tuntun jade. O ni lati jẹra kuro ninu rẹ gẹgẹ bi a ti ṣe ni gbogbo igba-ijọ, lati igba ijọ awọn ti o gba ojisẹ Ọlọrun Wesley gbọ ati bẹbẹ lọ. Ṣugbọn, ohun ti o jẹ ni pe, lẹhin ti a ba bi ibi tuntun ...... Wesley, tabi Luther jade pẹlu ọrọ kan: "Olododo yoo wa laaye nipa igbagbọ." O dara, ko le tun rọmọ eto atijọ mọ. O ni lati jade kuro ninu rẹ.

Lẹhinnaa, nigbati awọn ijọ Calvinists mu ijọ Anglican wa si iru ipo kan (labẹ ẹkọ Kalivini) titi o fi di igba ti Ọlọrun fi gbe ẹkọ Aminia jade (eyiti o jẹ Johanu Wesley). Eto atijọ ni lati ku ki àyè le wa fun tuntun lati jade. Nigbati igba-ijọ Wesley pari, gbogbo awọn igba-ijọ kekeke tabi awọn ewe kekeke ti o jade lara igi, tabi awọn-ẹ̀gbọ̀-ori-èso ni akoko Wesley.... Wo, nigbati Pẹntikọsti jade pẹlu awọn imupadabọ awọn ẹbun yii, wọn ni lati jade kuro ninu ijọ Onitẹbọmi, Ijọ awọn Alagba, ijọ Atipo-mimọ, Ijọ Nasarini, Ijọ ti Kristi (bi wọn ti ṣe n pe èé), ati gbogbo nkan wọnyi; wọn ni lati jade kuro ninu rẹ, jẹra kuro ninu rẹ, lati gba ibi tuntun!

29 Nigba gbogbo ni a n pe ọ ni asiwere, ṣugbọn o dabi Paulu ti o sọ pe nigbati o ti jẹra tan kuro ninu ohun ti o ti jẹwọ rẹ tẹlẹ ri; o sọ pe, "Ni ọna ti a n pe ni èké, eyi ni ọna ti mo fi n sin Ọlọrun awọn baba wa" - ni ọna ti a pe ni èké. Wo, o ti gba igbesi aye tuntun pe Majẹmu Laelae ti bi Tuntun, ati pe o ni lati jẹra kuro ninu ti Atijọ (o kan jẹ ojiji) ki aye ba le wa lati jẹ....

Eyi ni ibiti a wa bayi nisinsinyi. Bayi, ẹ farada pẹlu mi, ṣugbọn eyi jẹ imọran mi. Awọn ijọ ti ni ilana-eto to bẹẹ gẹ titi o fi jẹ wipe o ko le wọ inu ọkan ayafi ti o ba darapọ pẹlu ọkan. O ni lati ni kaadi-idanimọ ti idapo tabi iru awọn idanimọ kan. Ati nipa gbigba eyi gbọ, ilẹkun kan ti o fẹrẹ si silẹ ni awọn oniṣowo wọnyi. Niwọn igba ti

wọn ko ba jẹ ẹgbẹ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ, Mo le wọle pẹlu wọn ki n si mu isẹ-iwaasu ti mo lero pe o wa ninu ọkan mi fun awọn eniyan. Ṣugbọn o ti ni ilana-eto to bẹẹ gẹ ........ ati pe mo nifẹ ẹyin eniyan ijọ Pẹntikọsi. Ati pe Pẹntikọsti ki ṣe ẹgbẹ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ nigbakugba. Ẹ kan pe ara yin ni eyi ni. Pẹntikọsti jẹ iriri ati pe ki ṣe ijọ ẹlẹkọ adamọ kan.

Ṣugbọn o ri i, ohun ti o jẹ ni pe o nira fun ọpọlọpọ awọn ọkunrin, nigbati wọn ba wo o ti wọn si gba àá gbọ, ti wọn si ri pe Ọlọrun ti ṣe ìjẹ́rì-gbé ninu Ọrọ naa, sibẹ o nira pupọ lati jẹrà kuro ninu ohun ti o ti wa ninu rẹ tẹlẹ. “Kini Emi yoo ṣe? Nibo ni emi yoo ti ri ounjẹ mi? Kini...?” Ọlọrun ni ounjẹ rẹ! Ọlọrun ni ohun ti iwọ gbọdọ duro le! “Ẹ kọ wa Ijọba Ọlọrun ati ododo rẹ.” Emi yoo fi silẹ ki o simi nibiyi; o mọ ohun ti mo n sọrọ nipa rẹ!

30 A sọ fun wa nipasẹ awọn wolii Ọlọrun pe a o ni aye tuntun, ọrun tuntun kan ati aye tuntun kan. Ti o ba fẹ iwe- mimọ fun eyi, iwe Ifihan 21- ori ookan-le-logun ni o jẹ. Mo le sọ ayọka rẹ fun ọ. Mo ni nibiyi. Johanu sọ pe:

*Mo ri ọrun tuntun ati aye tuntun: nitori ọrun akọkọ ati ... aye akọkọ ti kọja lọ.“(O ti lọ.)*

Ni bayi, ti a ba fẹ ni aye tuntun, aye atijọ ati aye tuntun ko le jọ wa laaye papọ ni akoko kanna - tabi, aye tuntun ati aye atijọ ko le jọ wa laaye papọ ni akoko kanna. Ko le si awọn ilana eto aye meji papọ ni akoko kanna. Bayi, lati le gba aye tuntun, ti atijọ ni lati ku. Bayi, ti aye ti atijọ ba ni lati ku, lẹhinna o n ni awọn irora ibimọ fun tuntun miiran lọwọlọwọ.

31 Ati lẹhinna ti dokita kan ba lọ ṣe ayewo fun ẹnikan ti o n rọbí lọwọ, bayi ikan lara awọn ohun ti dokita yoo ṣe — eyiti mo n sọrọ niwaju meji tabi mẹta, eyiti mo mọ, awọn dokita onișegun ti o dara nibiyi, awọn dokita Kristiani. Emi yoo beere eyi lọwọ rẹ. Ikan ninu awọn ohun akọkọ ti dokita yoo ṣe lẹhin igba ti o ba ti n wo ẹniti o n rọbi ni lati ṣe ìdíwọ̀n akoko fun awọn irora naa bi wọn ṣe pọ to, awọn irora ibimọ. O fun awọn irora naa ni ìdíwọ̀n-akoko, bawo ni wọn ṣe sunmọ ara wọn si to ati bi ìdíwòn kọọkan ṣe n dunni si to. Ikan maa n nira lati ni ju ekeji lọ; eyi ti o tẹle, si tun nira sii. Wọn n sunmọra si. Eyi ni ọna ti o le fi ṣe ayẹwo ibimọ naa, nipasẹ awọn irora ibimọ.

O dara, ti ayé ogbologbo ba lee kuro ki aye tuntun le wá, jẹ ki a kan wo diẹ ninu awọn irora ibimọ ti a n lakọja ni orilẹ aye. Lẹhin eyi, a oo ri ọjọ ti a wa ati pe nibo lode ninu ìrọbí rẹ.

32 Ogun Agbaye akọkọ fi irora-ibimọ nla han. O fi ọkan ninu awọn irora-ibimọ akọkọ han pe o nlọ sinu irọbi, nitori akoko yẹn to wa fun u a mu awọn àdó-iku jade wa, ati pe a ni awọn ẹ̀rọ ti o ni ìbon ati afẹfẹ gaasi majele. Ati pe ṣe o ranti ... boya ọpọlọpọ ninu yin ko le. Mo jẹ ọmọde kekere ti ọjọ ori rẹ to ọdun mẹjọ, ṣugbọn mo ranti bi wọn ti ṣe maa n sọrọ nipa musitadi ati gaasi chlorine ati bẹbẹ lọ — bi o ṣe dabi pe o kan sẹsẹ bẹrẹ ati pe wọn sọ pe yoo sun gbogbo aye. Yoo pa gbogbo eniyan. O dara, o le jẹ pe eyi sẹlẹ — awọn afẹfẹ kan fẹ kọja lori ilẹ-aye, ati bi gbogbo awọn eniyan ṣe n bẹru dé iku fun ohun ija nla ti gaasi majele naa. Ayé la irora-ibimọ akọkọ rẹ kọja.

A tun rii wipe, a ti ni Ogun Agbaye keji. Ati pe awọn irora rẹ tun pọ si, o banilẹru si ni gbogbo igba, awọn irora-ibi ti aye. O fẹrẹ le pari ni akoko ado-iku nitori pe yoo pa odindi ilu kan run. O lagbara pupọ ju awọn irora Ogun Agbaye akọkọ ti iparun si aye.

33 Bayi, o mọ pe akoko itusilẹ rẹ ti wa ni ìtòsí. Idi niyi ti ara rẹ ko fi balẹ, bi o ti jẹ aifọkanbalẹ, o jẹ nitori pe ado-iku ti afẹfẹ ihidirogini - hydrogen ati awọn ado-olóró tinu afẹfẹ ti o le pa gbogbo agbaye run. Orilẹ-ede kan n bẹru ti ekeji, laibikita bi o ti kere to. Wọn ti ni awọn ado-olóró wọnyi ti wọn jẹwọ wipe o le ṣe e — ọkan ninu wọn, wọn le ṣe itọsọna wọn nipasẹ awọn irawọ ati ki wọn si ju wọn silẹ nibikibi ti wọn ba fẹ ni agbaye.

Ilu Rusia, bi mo ti gbọ ninu iroyin laipẹ yi, o jẹwọ pe oun le pa orilẹ-ede yi run ki oun si da àbò bo awọn afẹfẹ-atọmu tabi awọn nkan bẹẹ kuro ninu pipa orilẹ-ede rẹ run. A ko mọ ohun ti a le ṣe nipa rẹ. Onikaluku n ṣe ijẹwọ awọn nkan wọnyi, ati pe o ri bẹ. Awọn eniyan ni.... Awọn onimọ-ijinlẹ ti wọ inu yàrá-isẹ ti Ọlọrun ti o tobi titi wọn yoo fi pa ara wọn run.

Ọlọrun maa n gba laye nigbagbogbo ki ọgbọn pa ara rẹ run. Ọlọrun ko pa ohunkohun run. Eniyan maa n pa ara rẹ run nipa ọgbọn gẹgẹ bi o ti ṣe ni ibẹrẹ, mu ọgbọn Satani dipo Ọrọ Ọlọrun.

Bayi, o mọ pe oun gbọdọ parẹ. Oun ko le duro.

34 Ilu Rusia, mo gbagbọ, yoo pa orilẹ-ede yii run loni ti o ba gbero pe oun le pa a run lẹhinna ki oun si pa ara tirẹ mọ. Eyikeyi ninu awọn orilẹ-ede kekere wọnyi le ṣe, ṣugbọn wọn bẹru nitori wọn mọ pe aye yi ko le duro lori ọpa rẹ labẹ iru awọn ipo bawọnyi. Nitorinaa aye mọ pe awọn irora ibimọ rẹ tobi pupọ o ni lati parẹ. Laipẹ, a o bi aye tuntun kan.

Mo dupẹ fun eyi. Aye eyi ti su mi. Onikaluku mọ pe ibiyi jẹ ti iku ati ibanujẹ ati gbogbo iru awọn àdàmọ̀dì ati bẹbẹ lọ. Inu mi dun pe o ni lati parẹ; Inu mi dun pe akoko ti sunmọ. Gẹgẹ bi Johanu ti sọ ni atijọ, "Maa bọ, Jesu Oluwa."

35 Bayi, o gbọdọ jẹra, bẹẹni (bi mo ti ṣe sọ), lati le mu ìbí tuntun jade wa. Wo inu ohun ti o jẹra si. Ṣe akiyesi, arakunrin mi. O ti jẹra patapata! Iṣejọba rẹ ati awọn ètò isiṣe rẹ ti di ibajẹ lọpọlọpọ! Ko si egungun ti o lagbara ninu rẹ — ninu awọn eto agbaye rẹ! Iṣejọba rẹ ati oṣelu ẹsin rẹ ati ohunkohun ti o wu ko jẹ. Ọkan sọ pe, "Emi jẹ ọmọ ẹgbẹ ijọba tiwa-n-tiwa"; "Mo jẹ ọmọ ẹgbẹ iṣelu ijọba onisọkan"; "Mo jẹ ti ijọ Eleto"; "Mo jẹ ti ijọ Onitẹbọmi." Kilode, gbogbo rẹ ti bajẹ de oju àmìn! Nkankan ni lati fi àyè silẹ! Ko le gba àá duro. Ti o ba fi George Washington tabi Abraham Lincoln si gbogbo ilu kọọkan ni Amẹrika yi, ko le si atunṣe! O ti kọja irapada! Ohun kan soso ni o le ṣe iranlọwọ fun u, eyi ni wiwa ti Ẹlẹda! Àmín.

O mọ pe ohun gbọdọ kuro. O wa ninu irora ati ipọnju. Onikaluku ko mọ ohun ti o le ṣe. Ẹnikan n wo ọna yi, ati ẹlomiiran ni ọna yẹn, ati ohun gbogbo; ọkan n bẹru ekeji, ọkan gbiyanju lati ṣe nkan tabi pa eyi run, ati eyi n gbiyanju lati tako iyẹn ki o si pa ekeji run, titi o fi di isinsinyi wọn ti wa fi si ọwọ awọn ọkunrin ẹlẹṣẹ ti o le pa gbogbo agbaye run ni iseju marun si akoko ti a wa yi. Wo?

Nitorinaa o mọ pe oun ko le duro mọ. Awọn eniyan mọ pe ko le duro mọ, ati pe gbogbo aye mọ pe yoo sẹlẹ.

36 Nitori Ọlọrun sọ pe yoo ri bẹ. Gbogbo ọrun ati aye yoo wa ninu ina. Yoo jẹ isọdọtun gbogbo nkan ki a le bi aye tuntun. Ọlọrun ti sọtẹlẹ rẹ.

O di ibajẹ ninu gbogbo awọn eto rẹ ati pe o ni lati ṣe bẹ lati le jẹ ki o jẹra kuro. Nitorinaa idi niyi ti mo fi sọ pe o ni aifọkanbalẹ pupọ ati pe o ni pupa ni oju ati iporuru-ọkan ati awọn iwariri-ilẹ nibi gbogbo ni oke ati ni isalẹ eti okun ati awọn ìgbì omi ni Alasika ati mímì si oke ati si isalẹ eti okun pẹlu awọn iwariri-ilẹ ati awọn nkan ti awọn eniyan kọwe, "Sẹ ki a fi silẹ? Ṣe ki a fi silẹ?" Wo, wọn ko mọ kini ohun ti a le ṣe. Ko si ibi aabo ṣugbọn Ọkan, eyi ni Kristi, Ọmọ Ọlọrun alaaye. Ati pe ohun kan soso ni o wa ti o jẹ ibi aabo, ati pe Oun ni; gbogbo awọn ti o wa nita eyi ni yoo parun pẹlu idaniloju gẹgẹ bi Ọlọrun ti sọ bẹ.

37 Bayi, ẹ jẹ ki a wo iwe dokita (ti o ba wa ninu iru ipo yi) ati ki a si ri boya eyi yẹ ki o sẹlẹ nigbati a ba fẹ bi aye tuntun. Iwe ti Matteu ori kẹrin-le-logun-24 ninu iwe dokita, eyiti o jẹ Bibeli, ati pe ẹ jẹ ki a wo ohun ti a ti sọ asọtẹlẹ rẹ, kini awọn aami rẹ yoo jẹ. Bayi, ti dokita ba mọ awọn aami ti ibimọ ọmọ kan.... Ati pe nigba ti o ba di akoko ti ọmọ naa yoo wa, o mura ohun gbogbo silẹ nitori o mọ pe akoko naa ni a o bi ọmọ naa nitori gbogbo awọn aami ni o ti fi han. Omi tun jade, ẹjẹ, ati pe o ti to akoko — ọmọ naa n bọ nita, o ti to akoko lati bi ọmọ naa. Ati nitorinaa o mura ohun gbogbo silẹ fun un.

Bayi Jesu sọ fun wa ni pàtó ohun ti yoo ṣẹlẹ ni akoko yi. O sọ fun wa ninu iwe ti Matteu ori kẹrin-le-logun-24 pe Ijọ (Ijọ otitọ) ati ijọ miiran yoo jẹ — ijọ ti ara, Ijọ ti Ẹmi - yoo jọ sunmọ ara wọn (awọn aláfarawé) titi yoo fi tan awọn ayanfẹ jẹ ti o ba ṣeeṣe. Bi o ti ṣe ri ni awọn ọjọ Noa; bi wọn ti ṣe n jẹ, mimu, ṣe igbeyawo, fifun ni igbeyawo, ati gbogbo awọn iwa-irira ti aye ti a ri loni, Bibeli Iwe naa (iwe dokita) sọ pe yoo sẹlẹ. Nitorinaa nigbati a ba ri pe eyi n sẹlẹ a mọ pe ibimọ wa ni itosi! O ni lati sẹlẹ. Bẹẹni, sa.

Bayi, a wo eyi gẹgẹbi orilẹ-ede kan — kii ṣe orilẹ-ede kan, ṣugbọn agbaye kan.

38 Bayi Israeli, ijọ naa, jẹ ki a tun bẹrẹ pẹlu rẹ ni iseju diẹ ki a tẹle e fun iseju mẹwa siwaju tabi. Israeli ni awọn irora ìbímọ labẹ woliii kọọkan ti o wa si aye. O ni awọn irora ibimọ ni abẹ isẹ-iransẹ rẹ. Kini ohun ti o ṣe? Wolii ní Ọrọ naa ati pe Israẹli ti fi ara rẹ fun ibajẹ pupọ ati pe o ti ni awọn agbelẹrọ ilana eto pupọ ninu ara rẹ, titi woliii fi ti i kuro lori ipilẹ rẹ! Gbogbo eniyan korira wọn. Nitorinaa, nigbati Ọlọrun ba ran woliii kan, ijọ funrararẹ a lọ sinu awọn irora ibimọ nitori woliii naa — Ọrọ Oluwa tọ woliii wa ati oun nikan. Eyi ni pe, Ọrọ ti a sọ fun ọjọ naa ni a fihan nipasẹ woliii ti akoko naa — bi o ti ṣe maa n ri nigbagbogbo. Ati gbogbo ijọ, wọn ti kọ́ ọpọlọpọ awọn ilana ètò yika Ọrọ naa titi o fi gbọn ọ kuro lori ipinlẹ rẹ nigbati o ba de! O ni awọn irora ibimọ.

Kini eyi? "Pada si Ọrọ naa! Pada si iye!" Awọn ilana eto ko ni iye! Ọrọ Ọlọrun nikan ni o ni iye! A ti kọ́ ilana ètò yika rẹ, ṣugbọn ko ni iye. O jẹ Ọrọ naa ti o fun ni ni iye!

Isẹ iransẹ rẹ dari awọn iyokù pada si Ọrọ naa. Ẹgbẹ kekere kan yoo jade nigba miiran wọn a si gbagbọ, tabi — ni akoko Noa eniyan mẹjọ nikan. Ṣugbọn lọnakona Ọlọrun dáàbò bo ẹgbẹ kéré́je o si pa awọn iyoku run. O ni lati dari rẹ kuro.

39 O ṣe eleyi ni gbogbo awọn ìgbà atijọ titi o fi di igba ti ijọ fi bi ọmọ kan fun wọn, ati pe Ọmọ okunrin naa ni Ọrọ funrararẹ ti o di ara. "Ni atetekọṣe ni Ọrọ wa, Ọrọ naa si wa pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa. Ọrọ naa si di ara, o si n ba wa gbe." O sẹgun gbogbo esu, gbogbo agbara lori ilẹ aye ti o ṣe lodi si I pẹlu Ọrọ Baba nikan. Gbogbo idanwo ti Satani gbéwá fun U, O ba Satani wi, kii ṣe pẹlu awọn agbara tirẹ ti O ni, ṣugbọn pẹlu Ọrọ Ọlọrun. "A ti kọ wipe! A ti kọ wipe! A ti kọ wipe!" Nitori Oun ni Ọrọ naa!

Nigbati Satani fò lọ si ọdọ Efa, kii ṣe Ọrọ naa, nitorinaa ko yege. Nigbati o fò lodi si Mose, ohun kanna ni o ṣe. Ṣugbọn nigbati o kọlu Ọmọ Ọlọrun yii, o jẹ ẹgbẹrun mẹwa osuwọn iná. O lu awọn iyẹ ẹyẹ ti ko duro sinsin kuro ninu rẹ. Nigbati O pada de, ti O sọ pe, “A ti kọ ọ pe, 'Eniyan ki yoo wa laaye nipa akara nikan ṣugbọn nipa gbogbo ọrọ ti o jade lati ẹnu Ọlọrun!” Nibẹ ni a ti sọ ọmọ okunrin naa di ara, Ọrọ Ọlọrun ti ayeraye funrararẹ farahan ninu agọ ara lori ilẹ-aye lati ṣe asoju Ọrọ naa!

40 Bayi ni O ṣe mọ ohun ti o wa ninu ọkan wọn. Bayi ni O ṣe le sọ fun Filippi ibiti o wa, tani o jẹ; O le sọ fun Simoni Peteru ẹniti o jẹ; sọ fun obinrin naa ni eti kanga. Kini? Oun ni Ọrọ naa! Bẹẹni. Bibeli sọ ninu Heberu ori kẹrin: “Ọrọ Ọlọrun mú, o si lagbara ju idà oloju meji lọ, o si n pinya paapaa titi de ọra inu egungun, oun si ni olumọ ero inu ati ète òkan.” Kini, awọn alufaa Farisi ti o fọju naa ko le ri pe eyi ni Ọrọ naa ti a fihan, nitori a ti yi wọn pọ sinu ipo alufaa kan ati eto kan, ati pe eto atijọ ni lati lọ kuro. O jẹ Ọrọ naa, ṣugbọn ohun ti a ti ṣe ileri rẹ a ti mu u sẹ; nitorinaa ti a ba ti mu u sẹ, o ni lati jẹra danu. O jẹ epo; irugbin naa tẹsiwaju.

Mose ko le mu iwaasu Noa wa. Bẹni Jesu ko le mu iwaasu Noa wa, nitori pe o jẹ ti igba miiran; irugbin atijọ naa si ti pọn, ṣugbọn o mu idi iwalaaye rẹ sẹ o si ti ku, o si ti lọ. Iyipopada lati atijọ si tuntun, nibiti iye wa, ni ohun to n yọ awọn eniyan naa lẹnu nigba naa, kinni ohun to si tun n yọ wọn lẹnu loni sibẹ? A ko kọ́ odi kan, bi a ṣe bẹrẹ pẹlu isẹ iransẹ ojisẹ Ọlọrun fun igba naa Luther, lọ si isalẹ ni ìlà taara tabi isẹ iransẹ ti Pentikosti taara... A n yi awọn igun kan bayi! A n kọ ile kan! Ọrọ Ọlọrun ni iwe-akọsilẹ! Ẹnikẹni le sare lọ ni ìlà taara, ṣugbọn o gba akọsẹmọsẹ lati yi igun naa! Yoo gba agbara Ọlọrun lati ṣe eyi! Yoo gba ẹni itamiororo lati ọ̀run ti a fi ranṣẹ sọkalẹ wa lati ṣe eyi. O maa n ri bẹ ni gbogbo igba ijọ.

Ati ni igba awọn woliii, Ọrọ Oluwa tọ awọn wolii wọnyi wa, wọn si yi awọn igun yi po, ṣe awọn iyipada wọnyi. Ṣugbọn awọn akọle fẹ lati kọ odi kan. Kii ṣe odi rara; ile ni, ile Ọlọrun.

41 Bayi, a ni imọlara a si tun mọ pe eyi jẹ otitọ, ati pe awọn ọna-eto nigbogbo igba ijọ ja si asan, ati pe gbogbo ọna-eto wọn kọọkan ni lati jẹra ki o si ku danu, titi ti o fi mu Ijo naa jade, lati inu ibajẹ ti o ti jẹra yi, Ọrọ naa jade wa funrararẹ. Ọrọ Oluwa tọ awọn woliii wa. Ko tọ awọn alufa wa; o tọ awọn wolii wa. Kiyesii, ati nigbati o ba ṣe eyi, nikẹhin a bi Ọrọ naa lapapọ nibiyi bi ẹran ara eniyan. Ẹkunrẹrẹ Ẹniti-Ọlọrun-Jẹ ti O gbe inu Rẹ. Oun ni Ọrọ naa. Awọn wolii jẹ ara ti Ọrọ naa, Ọrọ fun akoko ti wọn. Awa loni jẹ ara ti Ọrọ naa, a tẹle Ọrọ naa. Ṣugbọn Oun jẹ ẹkunrẹrẹ Ọrọ naa ni kikun! Oun ni Ọrọ naa! O sọ pe, nigbati wọn n fi ẹsun kan An pe O fi ara Rẹ dogba pẹlu Ọlọrun nitori O jẹ Ọmọ Ọlọrun, wọn sọ fun Un pe, “O dara, o sọ ara rẹ di Ọlọrun.”

O sọ pe, “Ṣe a ko kọ ọ sinu awọn ofin yin pe a pe awọn ti Ọrọ Ọlọrun tọ wa ni ọlọrun kekeke (awọn woliii) - ati pe bẹ ni wọn si jẹ — lẹhinna bawo ni ẹ ṣe le da mi lẹbi nigbati mo sọ pe Ọmọ Ọlọrun ni Emi?”

42 Nibiti ẹkunrẹrẹ Ẹniti-Ọlọrun-Jẹ n gbe inu Ọmọ Ọlọrun. Oun ni Ọlọrun ti a fi han ni kikun.

Eyi ni awọn irora ìbímọ ti o jẹyọ labẹ awọn wolii wọnyi — kinni, wọn jẹ ti Ọrọ naa wọn tọka si kikun ti ara wọn, kikun Ọrọ naa. Ati lẹhinna awọn ọna-eto naa ku nikẹhin titi o fi di igba ti Ọrọ naa fi di ara ti o si n gbe laarin wa.

43 Wo bi a ṣe fi han ninu Jakobu. Wo bi a ṣe fi han ninu Josefu. Ni gẹlẹ. Baba rẹ fẹran rẹ, awọn arakunrin rẹ korira rẹ laisi idi kan; o jẹ ẹni ti ẹmi, le sọ asọtẹlẹ awọn ohun ati itumọ awọn ala. Ati pe ko le ṣe alaima jẹ eyi; bi a ti ṣe bi i niyi. A ti yan an tẹlẹ lati jẹ eyi, ṣugbọn awọn arakunrin rẹ korira rẹ, nikẹhin a ta a ni ọgbọn owo fadaka (o fẹrẹ to ọgbọn owo fadaka) ati pe a gbe e dide, o wa joko ni ọwọ ọtun Farao. Wo, ninu tubu rẹ ni agbọ́tí kan ati alásè kan wa. Ọkan padanu ẹ̀mí rẹ ati ọkan gba itusilẹ. Jesu ninu tubu rẹ lori igi-agbelebu; ọkan lọ sinu iparun, ọkan lọ sinu ìyè. Ni gẹlẹ, lẹhinna a gbe e ga si ọrun, o si joko lori itẹ Ọlọrun. Nigbati O ba si tun n lọ, ariwo kan yoo jade, “Ẹ wolẹ lori eékún yin,” ati gbogbo ahọn jẹwọ. Ati nigbati Josefu jade kuro ni ibi itẹ ti o ba n lọ siwaju, kàkàkí kan a dun ati gbogbo orókún ni lati tẹriba; Josefu nbọ̀.

44 Bẹẹ gẹlẹ ni ọjọ kan ipè nla Ọlọrun yoo dun; awọn okú ninu Kristi yoo ji dide, gbogbo eekun yoo wolẹ, gbogbo ahọn yoo jẹwọ si Ọrọ yi. O dara kini O n bọ wa fun? Kini O n bọ wa ṣe?

Kiyesii, o mu Ọrọ pipe yi jade ti a sọ di ara labẹ awọn irora ìbímọ ti awọn wolii ti o bu jade, “O n bọ '; O n bọ '; O n bọ '.”Bayi, ṣugbọn ko ni wolii fun irínwó ọdun gẹgẹ bi itan ti ṣe sọ ati Iwe mimọ, lati Malaki titi di igba Johanu. Wọn kan ni awọn ẹlẹkọ imọ-jinlẹ Bibeli, awọn alufaa, awọn olusọ-aguntan. Bayi a le roo wo, laisi eyi, iru ipo ibajẹ wo ni ọna-eto rẹ ki ba ti wa. Irinwo ọdun laisi isẹ-iranṣẹ taara pẹlu “Bayi ni Oluwa wi” lati ọdọ Ọlọrun! Nitorinaa awọn alufa, awọn wolii, ati bẹbẹ lọ ti mu u lọ sinu ibajẹ nla. O ti jẹra.

45 Lẹhinna Johanu, Elijah ti a ṣe ileri ni Malaki kẹta, kii ṣe Malaki kẹrin, Malaki kẹta, 'nitori Jesu sọ ohun kanna ni Matteu ori kọkọnla nigbati oju idì ti Johanu n ri bàìbàì (bi mo ṣe gbagbọ pe “Awọn igba akọkọ” bi ọgbẹni Pemberton ṣe salaye) o si wi pe, “ Lọ beere lọwọ Rẹ boya Oun ni Ẹni naa, tabi ki a fojusọna fun elomiiran?” Wo? O si wipe ... Jesu, lẹhin ti o ti ran awọn ọmọ-ẹhin rẹ pada, lẹhin ti o ti sọ fun wọn pe ki wọn duro si ibi ipade naa ki wọn si wo ohun ti o n sẹlẹ ati pe “Lọ fi nkan wọnyi han fun Johanu, ati ibukun ni fun

ẹniti ko kọsè ....” O yipada o si wo awọn ọmọ-ẹhin Rẹ ati awọn eniyan ti O n ba sọrọ. O si wipe, Kini ẹyin jade lọ wo nigbati ẹ lọ wo Johanu?“ O wipe, ”Ṣe ẹyin jade lọ wo ọkunrin kan ti o ni asọ fẹ́lẹ́fẹ́lẹ?“ O si wipe,” Mo wi fun nyin, iru eyi ni o n duro ni awọn àfin-ọba.“ O wipe, ”Ṣe iwọ jade lọ wo eweko ori omi ti afẹfẹ n fẹ?“

Ti a ba fẹ sọ ni ọrọ miiran gbogbo oró kekeke ti o kọja ni o mi. Mo sọ fun ọ ti o ba kan wa ki o darapọ mọ ẹgbẹ wa a le fun ọ ni ẹkunwo ti o dara julọ. Kii ṣe Johanu! Ti iwọ ko ba ni waasu lodi si eyi ati iyẹn, o dara iwọ le wa darapọ mọ ẹgbẹ wa. Kii ṣe Johanu.

O wipe, “Nigbanna kini ẹyin jade lọ lati wo? Wolii kan? Mo si wi

fun yin, o ju wolii lọ. Nitori bi ẹyin ba le gba a, eyi ni ẹniti wolii sọ nipa rẹ o wipe, 'Emi yoo ran ojisẹ mi siwaju mi yoo si tun ọna Mi ṣe.'“Eyi ni Malaki ori kẹta ẹsẹ kinni 3: 1; kii ṣe Malaki ori kẹrin 4 rara. Iyẹn yatọ ... Nitori ti Elijah yi ba wa, a o jo aye run lẹsẹkẹsẹ, ati awọn olododo yoo rin lori eeru awọn eniyan buburu.

46 Nisinsinyi ẹ kiyesi, iṣẹ iransẹ rẹ ko ru wọn soke pupọ kuro ninu orun ẹ̀sìn wọn. Won kan sọpe, “Ọkunrin asiwère´ kan wa ni isàlẹ lọ́hún; jẹ ko kọjá. O pe ararẹ̀ ni wèré. O n gbiyanju lati ri àwon eniyan si inu odò nibẹ.” Ṣẹ ẹ kiyesi? “Idi ti, ko fi si ohunkohun fun okunrin arugbo yẹn. Idi ti, ko fi tilẹ̀ ni asọ to tọ lọ́rùn. Awọ̀ aguntan lo fi bo ara rẹ yiká. Idi ti o fi kúsẹ́ bi onisẹ tòlótòló. Ki lo fa a, ile ẹ̀kọ́ bibeli wo lo ti jade, iwe idánimọ̀ ijosin wo lo ni? A ko ti ẹ ni wà ni isọ̀kan ninu awọn ipàdé rẹ̀. A o kan jẹ́ ki o duró si isàlẹ nibẹ ki ebi si pa á”, kiyesi. Agbáye ko ti yipadà pupọ, bẹ si ni ilànà rẹ pẹlu ko yipadà. “Ṣugbon a o kan jẹ ki o dúró si isàlẹ̀ nibẹ. O n ko ni ohunkohun…”

Njẹ o mọ idi ti ko fi? Ranti pe, àlúfà ni baba rẹ̀. Ṣugbon kini idi ti ko fi tẹle ònà baba rẹ̀, eyi ti o jẹ aṣa fun wọn ni ọjọ́ wọnni? Nitori o ni ohun kan iwásu nla kan. O ni lati fi Mesiah naa han, nitori ti Ẹmi Mimọ ti sọ bẹ. Aśẹku kekere ti a ti mu pada wa nipasẹ isẹ ti a ran Gabrieli nisàlẹ̀ lọhùn mọ pe iyẹn ma ri bẹẹ. Nitorina a sọ fun wa nigba ti o jẹ bi ọmọ ọdun mẹsan o wọ inu aginju lọ leyin ti o ti pàdánù-ùn baba ati iya rẹ, pe o wọ inu aginju lọ toripé ó ni lati gbọ́ gélẹ́, toripé ninu gbọ̀ngàn n lá á ile ẹkọ bibeli ni bẹ ni wọn ko ba ti sọ wipe, “Nisisinyi, mo mọ pe iwọ lo yẹ ki o kéde Messiah naa. Isaiah wipe iwọ n bọ wa, nitorina iwọ ni yoo jẹ ohùn naa. Nisisinyi, njẹ o ko wipe arakunrin Jones ní bí kàn ba eyi mu ní gẹlẹ?” Ti a ó si rọ̀ ọ́ pẹlu irọrun. Ṣugbon oun ko kọ́ ilana wọn kankan. Iwaasu rẹ ṣe pataki pupọ. O wọ inu aginju lọ lati maa gbé.

47 Kiyesi, iwásù ù rẹ ki ṣe bi ti awọn ẹlẹ́kọ́ ọ bibeli. O n lo awọn afiwé. O wipe, “Ẹyin iran ejo” - O n pe awọn alufa naa ni ejo. Ọkan lara awọn ohun to buruju ti o ti ri ni aginju (okan lara awọn ohun to n yọ kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́) ni awọn ejo. O si wipe, “Eyi fẹ jẹ àfiwé to dárajù ti mo mọ.” O wipe, “Ẹyin iran paramọ́lẹ. Ta lo ti ki lọ̀ fun yin nipa ibinú tó n bọ̀ wá? Ẹ maa bẹrẹ sii wipe, 'A wá jẹ́ ti èyi ati ti tọhun,' nitori ti Ọlọrun ní agbara lati gbe awọn ọmọ dide fun Abrahamu lati inu òkúta wọnyi wa!” Awọn okuta wọnyi - awọn ohun ti o ti ri ninu aginju leti odò.

Pẹlu, “Aake naa (ohun ti o ti lo ni inu aginju) ti wa lori gbòǹgbò igi na, (o hun to ri ni aginjù naa) gbogbo igi ti ko ba ti so eso rere, (o mọ ibi ti o ti ri igi idana rẹ, kiyesi) a o gee lulẹ̀, a o si ju si inu ina.” - o mu igi idana wa lati inu rẹ. Kiyesi isẹ iransẹ ẹ rẹ kii ṣe ti awọn àlúfà rárá. O wa ni ibamu ìsẹ̀dá ninu aginju, ṣugbon oni isẹ iransẹ lati kede o si ni igbagbọ ninu isẹ iransẹ rẹ lati sọ ọ, “Pe bibọ Messiah ti sunmọ tosi titi ti o fi wa ní bí ni aarin yin nisisinyi. Mo sọ fun yin, ẹnikan wa to n duro laarin yin ti ẹyin ko mọ, bata ẹniti emi ko to gbe. Yoo ṣe iribọmi fun yin pẹlu Ẹmi mimọ ati ina.

“Tani eni naa, Johanu?”

“E mi ko mọ.”

48 Ṣugbọn ni ọjọ kan ọdọmọkunrin kan wa to n rin wa si odo, o da bi eniyan yẹpẹrẹ, gẹgẹ bi … Johanu onitẹ̀bọmi arugbo naa si n duro ni bẹ̀ lọ́hun, wolii alábùkun fun to jẹ́ arugbo, ó sì wo isọ̀da a Jọdani, ó si wipe, “kiyesi, iyẹn ni ọ̀dọ́-Àgùtàn Ọlọrun Ẹniti ó kó ẹsẹ ayé lọ!”

“Ba wo lo ṣe mọ, Johanu?”

“Ẹni naa ni inu aginju to sọ fun mi lati lọ ṣe ìtẹ̀bọmi ninu omi i wipe, ”Ẹniti iwọ yoo ri ti Ẹmi naa n sọkalẹ le ló rí, O n ni ẹniti yoo ṣe ìribọmi pẹlu Ẹmi Mimọ.“

isẹ iransẹ rẹ ko le e wa lati inu ero awọn ẹlẹkọ bibeli tabi awọn adabọwọ ilana eniyan. O ni lati wa lati ọwọ Ọlọrun tàràtà!

Kini idi, isẹ iransẹ rẹ ko mi wọn pupọ. Wọ̀n rò pé, “Ha, o wipe o n ri iyẹn; Mo siyemeji sii gan an. E mi ko ri ohunkohun. Mo wo gbogbo…. Emi ko le e ri ohunkohun nipa rẹ,” awọn àlúfa ati awọn yooku wipe. Ṣugbọn o n ri i, a wa si mọ nisinsinyi pe o ri i. Dájúdájú o ri i. Ṣugbọn ṣe o kiyesi ohun to ri? Ko ru wọn soke kuro ninu orun wọn; wọn tẹsiwaju, won ge ori rẹ kuro bakanna. Ṣugbọn ko rú wọn śokè.

49 Ṣugbọn o ri awọn to o sẹku, awọn ti wọn ni ìyè ninu wọn, awọn agbo kékeré, Anna ati Simoni, ati awọn

diẹ ti wọn n duro de e bíbọ̀ Oluwa.

Ati Anna ninu tẹmpili, afọju, wolii obinrin tó n sín Oluwa pẹlu adura. Ni ọjọ kan nigba ti o wa ninu Ẹmi … Simoni si ti sọ asọtẹlẹ o si wipe, “Ẹmi Mimọ sọ funmi pe ”Emi ko ni ri iku titi ti n o fi ri Kristi Oluwa.“

“O dara,” awọn kan ninu awọn alufa, ṣe o mọ, wipe, “Arugbo yẹn, o un kan jẹ arakunrin kekere kan ni, ṣe o mọ. Ki ni idi, ẹsẹ kan rẹ ti wa ninu iboji bayi, ẹsẹ keji si n mì. kini idi, sa fi silẹ. O n ti jẹ arugbo okunrin to niyi tẹlẹ, ṣugbọn o jẹ iru u…” Ṣugbọn ṣe ẹ ri i, kini o ni? A fi han lati ọwọ Ẹmi Mimọ wa.

Eyi ni ohun kanna ti a n fi han yin ni ọ̀sán yii. Ẹmi Mimọ mu yin wa sibi fun awọn idi kan. Fun awọn kan… Ẹmi mimọ…Wo awọn iranṣe Ọlọrun to wa nibi lati ijọ Elétò, Onítẹ̀bọmi, Àgùdà, ati awọn yòókù. Ẹmi Mimọ n dari wọn. Wakati na ti de, nitorinna Ẹmi Mimọ rin n dari wọn, wọn si ti n wa, ebi Rẹ n pa wọn. Nigbanna lai pẹ…

50 Ni ọjọ kan - o mọ, wọn kò ní móhùnmáwòrán (Oluwa ṣeun) fun ọjọ yẹn. Nitorinna, wọn wa lori oke ti Judea. Ọmọkan wa ti a bi, Irawọ kan farahan, ati bẹbẹ lọ. Ṣugbọn lẹyin ọjọ kẹjọ, iya ọmọ naa gbe ọmọ naa wọle, a fi ọ̀já wé e. A sọ fun mi pe ọ̀já ni, iyẹn jẹ… Wọn ko ni ohun ti wọn yo wọ. O jẹ akisa kekere kan ti a mu lati ara ẹgbọrọ-maalu, bẹ la sọ fun mi, eyi ni asọ ọja yi. Nibi ni Josefu ati awọn yoku n wọle e bọ wa pẹlu ọmọ tuntun yii.

Mo le ro bi iya ọmọ naa ṣe duro sẹyin nibi tó jìnnà diẹ si iwaju pẹlu awọn ọmọ wọn pẹlu isẹ okinni ati gbogbo ẹ. O wipe, “Wo ibẹ, kiyesi. Kiyesi, ibẹ lowa. Wo ọmọkunrin yẹn lófún un lóyún. Oun lo si n wọle bọ yẹn, ẹ kuro lọdọ re. Ẹ jinna si. Ẹ ta kete si.” Wọn si tún n ro ohun kanna!

Ṣugbọn, Maria pẹlu ọmọ naa ni ọwọ́ rẹ mejeeji, ko ja mọ n Kankan ohun ti wọn n ro. Òún mọ ọmọ Ẹniti I ṣe!

51 Bẹẹ si ni gbogbo onigbagbọ to gba Ọrọ Ọlọrun si inu ọkan wọn! Mi o mọ ohun ti awọn àgbékalẹ́ sọ, wọn mọ ohun to jẹ! O jẹ ileri Ọlọrun. A fi han fun ọ lati ọwọ Ẹmi Mimọ wa nigbati agbara ṣiji bo ọ. O mọ ibi ti o wa. Ẹnikẹni ko ni ẹtọ lati wasu ìhìnrere titi ti yoo fi ba Ọlọrun pade ni ibi aginju ninu igbo to n jo, ni ibi ti ko si eto ijọ aye kan kan to le salaye rẹ kúrò lọ̀dọ̀ rẹ. O wa nibẹ. O sẹlẹ si ọ! Emi ko fẹ mọ ohun ti awọn ilana naa n sọ. Iwọ jẹ ajẹri rẹ! Hallelujah! Mo ni òhùn mọ̀ bi ọkunrin arúgbó aláwọ̀ ti mo un sọ nipa rẹ lasiko yi!“ Mo ni imọlara Ẹmi bayi, nigbati mo ro pe iyẹn tọ na, Ọlọrun fúnra Rẹ̀ lo fihan fun ọ.

52 Símónì ni ìlérí naa, oun joko ni yàrá ìkàwé rẹ ni òwúrọ̀ ọjọ yẹn. Bẹẹ ni, mo ro pe ọpọlọpọ ni wọn ma n gbe wa ni gbogbo owurọ, bi miliọ̀nu meji ati abọ awọn ọmọ Juu lo wa ni orilẹ ede naa, awọn ọmọ wọnyi si n wa, ti a si n bi ọpọlọlọpọ. Ni gbogbo ọjọ kẹjọ iya ọmọ ni lati wa, ki o si mu ọrẹ wa fun ìwẹ̀nùmọ́. Bayi Simoni lo n bọ yi, ti o joko sibẹ, sé ẹ mọ̀, boya o n ka iwe Isaiah. E mi o mọ̀. Ṣugbọn gbogbo rẹ Lẹẹkanna…

Bayi, tí Ẹmi Mimọ ba ti ṣe ileri kan fun ọ, Ẹmi mimọ ni lati pa ileri naa mọ - ti o ba jẹ Ọlọrun nitotọ. Bi eniyan kan bá wá ti o si sọ ohun kan, ti Ọlọrun ko ti lẹyin, kì í ṣe ìwé mimọ lati bẹrẹ, gbagbe nipa ẹ̀. Ti o ba si sọ wipe o ri bẹẹ, ti Ọlọrun ko si ti lẹyin, o si tun lódi tori Ọlọrun lo n túmò Ọ̀rọ̀ Rẹ. Ti ohun tó sọ bá wá sí ìmúsẹ, nigbana Ọlọrun sọ pé ẹ gbọ́ Ọ nitori òtítọ́ ni. Iyẹn jẹ ohun to mu ọgbọn wa. Ti O ba sọ pe ohun kan yoo sẹlẹ ti o si sẹlẹ, ohun niyẹn. O gbọdọ jẹ otitọ ré̩gíré̩gí ni gbogbo ígbá nitori Ọlọrun ki i pa irọ.

53 Nigbana, eyi si ni Simoni to joko sibẹ to farada inúnibíni. O jẹ ẹni to ṣẹ́ kù. O gbọ Johanu, ati awọn to sẹ́ku ni ọjọ naa. Ati nihin o joko sibẹ to feti si iwe mimo yi, ohun mọ… Mo ro bẹẹ, ni mímọ̀ pé é Johanu n bọ 'toripe o jẹ ọkan lara awọn to ṣẹku; a fi Ọrọ naa han fun. Ati Lẹẹkan naa, nigbati ọmọ yẹn wa sinu tẹmpili (nigbana o jẹ ojuṣe Ẹmi Mimọ lati fihan pe o wa nibẹ)… Nitorina ó rìn nipasẹ Ẹmi naa, o jade wa lati inu iyara ikawe rẹ, o wọ gbòngàn naa lọ, o kọlu ila awọn obinrin, o tọ ila awọn obinrin naa lọ, titi ti o fide ibi ti ọmọ kekere yi wa, gbogbo won ni wọn n sá á fun, o gbe ọmọ naa ni ọwọ rẹ mejeeji, o wipe, “Oluwa, jẹki ìransẹ Rẹ lọ ni Alaafia nitori oju mi tirí ìgbàlà Rẹ.”

Ni asiko yẹn, ayanfẹ kekere miiran ni ọjọ yẹn ni Anna, wolii obinrin kekere kan. Oun joko si ibikan nibẹ, kò rí raǹ, ni kọrọ̀ kan, a bi ni afọju. Oun ló n bọ wá yí, Ẹ̀mí ló n darí rẹ, ninu gbogbo awọn obirin ti awọn èrò si kun inú ati ìta tẹmpili, titi ti o fi de ibi ti ọmọ naa ti I ṣe Kristi wà. Ti Ẹmi Mimọ ba le dari obinrin afọju si ọdọ Rẹ̀, bawo wa ni ti àkójọpọ̀ ẹgbẹ pẹ́ntíkọ́stì tó yẹ kó ní ojú rẹ ní pípé! Emi ko ni tẹsíwájú; ẹ mọ̀ lati ibẹ lọ.

Kiyesi, ah, bi ìjọ yẹn ṣe nilati wa ninu ìríra to burú Lẹẹkan si! Dájúdájú o nilati ri bẹẹ ni ọjọ yẹn. Ṣugbọn o kọlu awọn àsẹ́ku kekere naa, gẹgẹ bi mo ti wi.

54 Bayi, ẹ jẹ́ kí á sọ òtítọ́. Ti a ba ri ijọ yẹn ninu ipo yẹn loni, njẹ a ko tún ti bọ́ sí inú akoko yẹn Lẹẹkan si? Bayi, saa wo awọn nkan ti Bibeli ṣe ileri wipe yoo maa sẹlẹ ninu ijọ naa ni akoko yi. A ri ohun to n sẹlẹ ninu aye a si tun ri pe o ti de opin rẹ. Bayi ẹjẹ ki a wo inu ijọ. Obinrin (Ijọ naa) ni ìrora ìbímọ lábẹ́ ẹ Luther. Bayi, a mọ pe igba ijọ meje lo wa ati awọn iransẹ meje si awọn ìgba ijọ yẹn gẹgẹ bi iwe Ifihan ti sọ. Bayi nigbati

Luther ni lati jade wa, dajudaju o fi ijọ sinu awọn irora ìbímọ, ṣugbọn o mu Luther jade. Iyẹn tọ̀nà.

Lẹyìn iyẹn, o wọ inu wahala lẹẹkansi, nitorina o mu Wesley wa. Iyẹn tọna ó tẹ̀síwájú Lẹẹkan si, o si mu awọn a fi ìfèdèfọ̀ ṣe ẹri Ẹmi Mimọ jade wa. Ẹnikọọkan wọn (awọn iransẹ igba wọn) pada si inu Ọrọ, iwaasu ìgbà ijọ wọn, iwaasu naa gẹgẹ bi Bibeli ti wi. Mo ti ri, iwe kan n bọ wa lori iyẹn - àlàyé lórí ori mẹrin akọkọ iwe Ifihan. A ó ká laipẹ ni kete ti a ba ti tẹẹ tan, o si tayọ gbogbo iyèméji ohun ti ìwáasù Luther jẹ; idanìláre. Ìsọdimímọ́ ni ìpele tó kàn ninu ìbímọ ti ara, lẹyin eyi ni awọn a fi ìfèdèfọ̀ ṣe ẹri Ẹmi Mimọ. Bẹ́ ẹ̀ lórí.

55 Kiyesi nisinsinyi, ìgbà kọ̀kan ni ohun kan n ṣẹlẹ si ijọ tì o si n fun un ni awọn ìrora ìbímọ. Ṣugbọn kini wọn ṣe? Lẹyin igba ti ìrọbí wa, kaka ki wọn o ma tẹsiwaju pẹlu Ọrọ naa, wọn ko awọn eniyan jọ gẹgẹ bi alákọ́kọ́ ṣe ṣe. Bẹ gẹ́lẹ́ lórí. Lẹyin ti awọn aposteli ti mi lẹ̀ tìtì, lẹyin igbana a ri pé ó tún-ún lọ. Lẹyin naa a ri pe, ọpọ awọn miiran tun wa, Agabusi ati ọpọ awọn alatunṣe nla to wà ni ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Igbà kọ̀ọkan ti ṣe (Bi ẹ ṣe n ka iwe saju - Àjọ Nìkíà, awọn Baba Nìkía ati gbogbo awọn tàtẹ̀yin wá, o rí gbogbo rẹ̀ níbẹ) - igba kọkan mi tìtì ni gbogbo ìgbà ti ìránsẹ́ kọ̀kan bá jáde wá pẹlu u “Bayi ni Oluwa wi.”

Bayi, ó wà ní ìpele tó burú jù tó bẹ̀ gẹ́, gẹgẹ bi Iwe Mimọ ti wi, ju ti à tẹyìn wá lọ. A wa ni igba ijọ Laodekia, ìjọ́ tó lọ́rọ̀ ṣugbọn to jẹ ìgba ijọ afọ́jú ti ko si mo! Kò sí ibi kan ninu Bibeli ti a ti ti Kristi jade kúrò nínú ìjọ ri ṣugbọn igbà ìjọ Laodékìà. Ó wà ní ìgbà tó buru jù. Ohun ni ìdibajé tó buru ju tó ti i wà. O wípé “Mo joko bi ọbabìnrin, emi ko si nilo ohunkohun” o ko si mọ pe ìhòhò ati otòsì, afọ́jú, àre, iwọ kò sì mọ̀ ọn.“ Bẹni, alagba, ”Mo gba ọ ni imọnran, pe ki o wá ra oogun ikunjú lọdọ Mi ki Emi le ṣi oju rẹ“. Iyẹn yoo si ṣe e dajudaju…Ikunju Ọlọrun yoo mu ìmọ̀lè wa dájudaju si ijọ naa ti o ba fẹ la oju ararẹ̀ si ohun ti Ọlọrun ti wi.

56 Kiyesi kiakia bayi. Bayi, o wa ni ipele to tayo iyemeji, a wa ni igba ijọ Laodekia. Nisinsinyi, a ṣe ileri iransẹ rẹ ni ori kẹrin iwe Malaki… A ṣe ileri pe o un ni yoo ṣe e, isẹ iransẹ rẹ na si ni lati mu Ọrọ naa padà wa, mu awọn eniyan naa pada wa sinu Òrọ̀ naa. Ìbi ni lati wa… O gbọdọ di atunbi gẹgẹ bi Malaki ori kẹrin ti wi.

Ninu ijọ aye loni, agbekalẹ meji lo wa eyi to n sisẹ. Nisinsinyi feti silẹ dáradára. Bayi, mo fẹ rí bí ẹ̀yin yoo ba ṣe “Ámin” lori eyi. Ilana meji lo n sisẹ ninu ijọ aye loni (Emi yoo mu eyi kúrò léjìká mi, lẹyin naa ma dánu dúró lórí rẹ̀). Gbogbo wa la mọ̀ ìyẹn, ìyẹn ni Ọrọ Ọlọrun ati agbekalẹ aládámọ̀. Agbekalẹ meji lo wa loju isẹ. Gẹgẹ bi wọn ṣe wà - Jakọbu ati Esau - ọkan nipa ti Ẹmi, ekeji si wa nipa ti ara. Ki si ni. Esau ati Jakọbu n jà ninu oyún iya wọn títí dí ìgba tí wọ́n bí wọn. Bẹẹ naa si ni awọn ẹlẹyamẹya ati Ọrọ naa ti wọn n ba ara wọn ja. Wọn ti n ṣe bẹẹ lati igba ti Luther ti kọkọ mu atunṣe wa. Mo ni ireti pe iyẹn rọrun fun yin lati lóye e rẹ. Ṣe ẹ kíyèsi?

Awọn oniwaasu wọnyi, ti wọn ba mu eyi ti wọn si jade lọ pẹlu rẹ, wọn ni òye síwájú si. Kiyesi, lati mu wa síbì kan … Mo kan fẹ fi irugbin yi lọ lẹ, mo lé rò pe wọn le mu ko wa sáàyè.

Kiyesi.

57 Kiyesi, bo ṣe ma n ri niyẹn ni gbogbo igba. Ìdí nì yí tó fi n ni ìrora ìbimọ, nitori ija wa ninu rẹ! Esau kan wa, to jẹ eniyan aye lasan, o jẹ ẹlẹsin, ati pe, o jẹ arakunrin daradara, o mọ, ó ní iwà bí mo ṣe mọ̀ tó nipa rẹ, ṣugbọn ko mọ ohunkohun nipa oguń ìbí yẹn! Bi a ṣe bii niyẹn; bí a ṣe dá a nìyẹn. Ati Jakọbu, emi ko fẹ́ mọ ohun tó jẹ́, o n fẹ ogun ibi yẹn! Ó jẹ́ ẹni Ẹmí! Awọn mejeeji loni - si wa nínú ikùn ìjọ.

Agbekalẹ ńlá kan wà fẹ́ dá sílẹ̀ ti wọn n pè ni Akojọpọ Igbimọ Ìjọ Àgbáyé. Ati lati inu ijọ naa ni ọmọ meji ti n bọ wa. Ẹ ṣe àmì si ọrọ mi! Ọrọ naa gbọdọ mu Ìjọ Ọ̀rọ naa jade wa. Ijọ naa ni lati bi Iyawo fun Kristi lati inu rẹ wa. Awọn ti wọn ti sùn ni gbogbo ìgbà wa ni yoo jẹ àkójọpọ̀ Ìyàwó yẹn to jade lati inu Ọrọ naa ti a fi mú wọn jáde wa. Bi lati ẹsẹ̀ rẹ wa si ori rẹ. Ò kàn n tobi sii ni, o sì gbọdọ̀ ní si, ati bẹẹbẹẹ lọ. Gẹgẹ bi ara ti n dagba soke, bẹẹ ni ara Kristi ṣe n dagba soke. Ní òpin gbogbo rẹ̀ orí yoo tọ̀ ọ̀ wá - ori rẹ yoo wa.

Bayi, ti a ba ṣe akiyesi, 'tori gbogbo rẹ̀ so mọ́ orí naa, ori naa lo n yi ara, to si n fa a.

58 Ṣugbọn awọn agbekalẹ wọnyi ko ni dagba wa lati inú ìyẹn, nitori o jẹ agbekalẹ kò sì le e mu u jáde wá - èpò kan ko le mu alikama jade. Ṣugbọn wọn jọ wa lórí pápá kanna ni, omi kanna la fi rin wọn ati ìtansán òorùn kanna! Ọkan jẹ́ Òrọ̀ naa; ọkan ki si ṣe Ọrọ naa. Awon mejeeji lo n ja, wọn ti ń jà lati igba àtúnṣe àkọ́kọ́, wọn si n ja si bẹ naa.

Bayi, emi kò ní lati rin jinna lori iyẹn, sẹ́ mo láti ṣe bẹ? Nitootọ ẹ mọ ohun ti mo n sọ nipa rẹ. Ibẹ la wa. Ibẹ̀ ni agbekalẹ rẹ wa, ninu agbekalẹ wo lo wà?

Ìwọ kàn ro o nisinsinyi. Ti ìwọ bá ti gbe ni awọn ìgbà tó ti wa labẹ akoko awọn wolii Ọlọrun ati Ọrọ̀ lati jade wa, ìhà wo ni ìwọ kò bá fẹ́ lati wà nigbàńaà? O dara iwọ tun ni ìyàn kanna loni. Ó n múra lati mú Ọ̀rọ̀ pipé naa jáde wá, ọrọ naa si n bọ wa fun awọn Iyàwó Ọ̀rọ̀. Gẹgẹ bi obinrin ṣe jẹ ara ọkunrin (tí amú-un jáde lati ara rẹ̀) bẹ ni ijọ naa ṣe ni lati jẹ ijọ to n gbe ninu Ọrọ-gbogbo ọ̀rọ inu Bibeli! Ki ṣe àgbékalẹ̀, àdámọ̀, tabi

ohunkohun ti a fi kún-un. Yoo ni lati jẹ ogìdì, wúndía Ọ̀rọ̀ tí ko lábùlà! Sé ó ye ọ!

Ni awọn ọjọ ìmọ́lẹ̀ ti Luther nigbati ijọ yapa, Luther … Nítòtó ó la ìrora kọja. Ṣugbọn o jade wa pẹlu "Olódodo yoo wa nipa igbagbọ! Eyi ki i ṣe idapọ naa."

Bayi, a ri wipe ni igba awọn ọjọ ti John Wesly o tun mu ìrora wa Lẹẹkan si ṣugbọn Wesley kan wà tí a bí! Ṣugbọn ki ló ṣe? O pada lọ gẹgẹ bi ìyá naa ti ṣe.

Lẹyin naa ni akoko awọn afi ifedefọ sẹri Ẹmi Mimọ awọn baba yin ati awọn iya yin jade wa lati inu nkan yẹn wọn si kóríra rẹ̀! Wọn jade lọ si oju popo, iya yin ti ko ni ìbọ̀sẹ̀ lẹ́sẹ̀ rẹ̀, ó n lu ògbólògbó agolo, o si n sọ nipa ìrìbọmi ti Ẹ̀mí Mímọ́ - pẹlu awọn jìtá tó ti gbó. Wọn wa loju popo nibi ti awọn ọkọ̀ n wà - wọn wa ni àtìmọ́lé ni gbogbo alẹ́! Àwa sì ti gan púpọ̀ ti a si pada sẹ́yìn si inu àdámọ kan, a si ṣe ìdibàjẹ́ kanna si ara wa (wọ́n mú awọn ọmọ padà wọ ibẹ̀ lọ) ibi ti wọn ti jade wa! Ti wọn ba ji ninu iboji wọn loni! Ojú yoo ti wọn. Mo mọ pe eyi le ṣugbọn otitọ ni.

59 O wipe, "Mo ro pe o ní ìfẹ́ àwọn ènìyàn." Ti ìfẹ́ kò bá tọ́ni sọ́na, ba wo wa ni iwo yoo ṣe mu ifẹ jade? Ifẹ n tọni sọna, mo si n ni ifẹ ẹ gbogbo ayé. Mo n ni ìtara ijọ Ọlọrun. Ati lati ri àgbékalẹ̀ wọ̀nyí tó n de ijọ mọ́lẹ labẹ ẹ àdábọwọ́ to n jẹrà á lọ, Ọlọrun si n jẹ́wọ́ Ọ̀rọ̀ Rẹ̀ lati jẹ òtitọ́, sibẹ wọn dì í mú! Amin! Òtító ni ìyẹn. O mọ pe otitọ ni, arakunrin, arabinrin. Ìyẹn jẹ….Iyẹn jẹ́ ònà tó rọrùn láti sọ ọ́. Ki i ṣe fífọ̀ wẹ́wẹ́ ẹ ti Gíríkì ati awọn nkan miiran, ṣugbọn o jẹ́ fífọ̀ wẹ́wẹ ati fífi òye tó wọ́pọ̀ hàn. Dajudaju o le loye iyẹn. Ti a ba ro meji pọ mọ meji, mẹrin ni yoo fun wa, kiyesi. Bayi, a mọ pe iyẹn tọ̀nà.

Nisisinyi, Ọrọ naa gbọdọ mu Iyawo naa wa.

60 Ṣugbọn àgbékalẹ̀ àtijọ́ gbọdọ pa irú rẹ̀ mọ́, oni lati mu Esau kan jade èyí tó ta ogún ìbí rẹ.

Òhun ló n bọ̀ yí. Mo ni imọlara rẹ! Mo nírètí pé ẹ ò rò pé orí mi kòpé, ṣugbọn tí mo bá rí bẹ̀, ẹ fí mí sílẹ. Ó tẹ mi lọ́rùn báyí. Mo sàn ni ona yi ju bi mo ṣe wa tẹlẹ lọ. Mo le ya wèrè lójú ayé, ṣugbọn mo mọ ibi ti mo wà. Mo mọ ibi ti mo n duro si.

Wo, yoo mu àbíkú ọmọ jáde, agbekalẹ ijọ kan ti yoo mu gbogbo ẹlẹyamẹya papọ lati mu Esau kan to kóríra Jakọbu! Amin. Mo nírètí pe ẹ rí i. Àbíkú ọmọ, ẹlẹyamẹya to ti ku - gbogbo wọn si n lọ papọ.

Ho, Ẹyin onigbagbọ Ọrọ, ẹ gbọran iwaasu mi! Ẹ gbọ mi, ki ṣe iwaasu mi ṣugbọn iwaasu Rẹ eyi ti o ti fi idi rẹ mulẹ dájúdájú lati jẹ otitọ. O ni lati yan lati ibikan. O ko lee joko sójúkan lẹ́yìn eyi. O ni lati yan.

61 O ranti ọjọ́sí ni apa Ìwọ̀-òrùn Ho nibẹ (ni owurọ ọjọ naa gbogbo yin ti jẹ òùnjẹ á rọ̀) bi Oluwa ti jẹ ki n fi ọkà yẹn han yin, bi o ti wa lati ipasẹ Luther, Wesley, ati awọn ìrùkẹ̀rẹ̀, ati bẹbẹ lọ, awọn isun kekere naa to wa lati gbogbo ijọ ti o jẹ asoju lara erín àgbàdo naa, ati lẹyin ìgbà naa wọn lọ si ara ọkà naa gẹgẹ bi o ti ri, ìyàngbò kekere yẹn si ti wà to da bi ojulowo irú ọkà naa. Nigbati o ba jade lọ lati wo, ti iwọ ko ba mọ ọka rẹ; iwo yoo sọ pe, "iwọ ni ọkà nibẹ" - ṣugbọn ìyàngbò lasan ni. Ati lẹyin igbana ti o ba si iyangbo yẹn soke, ko si alikama nibẹ rara. Lẹyin lọ́hún ni irudi ìyè kekere kan ti n bọ wa. Iwọ mu dingi kan ko si wo o. Ati nigbati awọn afi ifedefọ sẹri Ẹmi Mimọ kọkọ jade wa, o súnmọ́ gan, Jesu sọ ni inu iwe Mathew 24:24, yoo tan awọn ayanfẹ papa jẹ ti o ba ṣeé ṣe.

Ki ni ohun ti yoo ṣe? Iranlọwọ fun iru ọka naa, ṣe è yí tọ̀nà? Bayi, awọn taseli naa … Wo ibi, ewé-àkọ́yọ, naa ko dabi irugbin to wọlẹ, bẹni tásẹ̀li naa ko jọ ọ; ṣugbọn o fẹ dà bi rẹ, ìyàngbò naa si jọ̀ ó gan-an. Ṣugbọn sibẹ ki iṣe alikama naa. O kàn jẹ́ ohun tó n gbé àlìkámà naa ni.

62 Ṣe ẹ o ri bi awọn iṣẹ-iranṣẹ wọ̀n yẹn ṣe ti wá pẹlu ìrora ibimọ? Ṣugbọn o fi ìyè naa silẹ lati wọ inu iṣẹ-iranṣẹ to kan lọ. Iye naa jade lati ọdọ Luther lọ si inu iṣẹ-iranṣẹ Wesley, lati inu iṣẹ-iranṣẹ Wesley lọ si inu iṣẹ-iranṣẹ awon afi ifedefọ sẹri Ẹmi Mimọ. Bayi akoko ti de lati fi ìyàngbò naa silẹ. Ki lo de? Isẹ̀dá wa ni gbogbo ona to n fi han ni gbogbo ọna pe otitọ ni yẹn.

Nisinsinyi ẹ ri idi …. O rò pe mo ya wèrè. Boya bẹẹ ni (gẹgẹ bi Mo ti sọ), ṣugbọn ohunkan wa ninu mi, emi kò le è dadúro. Emi kọ ni mo fi si bẹ. Ko wa lati inu ìyàn mi. ọlọrun ni! O si fi idi rẹ mùlẹ̀ lati fi han pe otitọ niyẹn - lati jẹ́ kó jẹ́ òtítọ. Kii ṣe pe mo ni ohunkohun lòdi si Luther ati Wesley, awọn afi ifèdèfọ̀ sẹ́ri Ẹmi Mimọ tabi awọn Onitẹbọmi, tabi ẹnikẹni- Emi ko ni ohunkóhun lòdi si ẹnikẹni; agbekalẹ ni ohun ti mo lòdi si nitori Ọrọ naa lòdi si! - Ki ṣe awọn eniyan naa! Wo awọn àlúfa ati awọn iránsẹ́ Ọlọrun to joko síbí loni. Wọn ki baa ti wa nibi ti wọn ba fetisi agbekalẹ, ṣugbọn wọn ni ìgboya to jẹ ti Ọrọ Ọlọrun lati jade wa ki wọn si gba! Hallelujah! Eyi tumọsi pe "ka yin Ọlọ̀run wa." Kò ní pa ọ́ lára. [Ẹnikan sọ pe, "amin."] o tumọsi "bẹ ni yoo ri, Mo gbà á gbọ́." Mo gbagbọ mo si mọ̀ pe otitọ ni! A fidi rẹ mulẹ pe otitọ ni! Ni ọjọ kan ẹ o ri pe bẹẹ ni - ṣugbọn ó ti lee pẹ́ jù.

Nisinsinyi, kiyesi, kiyesi.

63 Bibeli wipe iyawo Rẹ ti múra tán ni òpin ìgbà ijọ yii. Bawo lo ṣe múra silẹ?... lati di iyawo rẹ. Ati irú asọ wo ló wọ̀ sọ́rùn? Ọrọ Rẹ. Ó wọ Ododo Rẹ? Iyẹn ni ohun to jẹ, sé o kíyèsi? Awọn iran.

Kiyesi. A ti n parí bayii. Mo fẹ sọ ohun kan yi, ki a to pari. Iyẹn ni ohun to mu mi sọ eyi. Mo ni "BAYI NI OLUWA WI" Bi ẹnikan yoo ba sọ iyẹn lá ì fi si inu èrò ararẹ̀, yoo jẹ alágàbàgebè o si yẹ ko lọ si ọ̀run àpáàdi nitori rẹ̀. Bẹ ni. Ti yoo ba gbiyanju lati ko ọpọ eniyan jọ, awọn eniyan to dara bi eyi, ti yoo si tàn wọn jẹ, nitorinaa, yoo jẹ eṣu ninu ẹran ara eniyan, Ọlọrun ki yoo bu ọla fun un. Sẹ o ro pe Ọlọrun yoo bu ọla fun eṣu kan tabi òpùrọ́ kan? Laelae. Kiyesii, o wọ kọja oye wọn, wọn ko si loye rẹ, O fa awọn ayanfẹ jade.

64 Wo gbogbo awọn wolii ni gbogbo igba ijọ bi O ṣe gba awọn ayanfẹ. Wo, ki a to wa si igba atunto, gẹgẹ bi ijọ Aguda a Romu ṣe jo Joana ara Arc mọ́ igi fun pe ó jẹ́ àjẹ́. Otitọ ni. Nigba to yá wọn ri wipe kii ṣe bẹẹ; obinrin naa jẹ ẹni mimọ. Wọn wa ṣe atunṣe ifiyajẹ-ara-ẹni, wọn gbẹ iboji awọn alufaa, wọn wu oku wọn jade, wọn si ju wọn sinu odò, ṣe o mọ, ṣugbọn eyi ko yanju rẹ ninu iwe Ọlọrun. Rara!

Wọn pe Patrick mimọ naa ni ọkan pẹlu, sẹ ẹ ri, o si fẹ jẹ bi emi naa gẹgẹ ṣe jẹ ọkan. Nitorina, a sa kiyesi… wo awọn ọmọ rẹ; wo ibiti wọn wa; wo iye awọn ti wọn ti pa; wo ẹ̀kọ́ lori awọn ajẹ́ríkú ki o si wo iye awọn ti wọn pa nibẹ. Kiyesi, ko ri bẹ. Ṣugbọn ohun ti awọn eniyan naa sọ, ko sọ pe o rí bẹẹ, o jẹ ohun ti Ọlọrun sọ to si fi idi rẹ mulẹ pe o jẹ otitọ. "Ẹ wa di ohun gbogbo. Di eyi ti o tọ mu."

65 Bayi, a ri nibi ni nkan bi osu diẹ sẹyin, ni owurọ ọjọ kan mo n rìn jade lati inu ile iran kan si wa. Mo pe ẹnikẹni níja nibi to mọ̀ lati gbogbo awọn ọdun yi wa lati sọ pe igbà kí gbà ti Oluwa ba mú mi sọ pe "Bayi ni Oluwa wi" ṣugbọn ti o maa n ṣẹlẹ. Eniyan melo lo mọ pe otitọ ni, ẹ na ọwọ yin soke. Ṣe ẹnikẹni le sọ ohun to lodi? Otitọ ni.

Maṣe kiyesi si ìránsẹ́ naa; wo iṣẹ ti a fi ran an. Iyẹn ni ohun ti ojẹ. Ki i ṣe iyẹn. Maṣe kiyesi apari kekere naa (ṣe o mọ) ẹni nitori o kan jẹ eniyan lasan, ṣe o mọ, bákanná ni gbogbo wa ṣe ri. Ṣugbọn kiyesi ohun to n sẹlẹ. Iyẹn ni ohun to fidì rẹ̀ múlẹ̀.

A mu mi. Bayi, Mo mọ pe awọn eniyan n sọ orisirisi nkan, a si mọ pe ọpọlọpọ rẹ ni ko tọna. Emi ko le dahun fun ohun ti ẹnikẹni básọ. Mo nilati dahun fun ohun ti mo ba sọ. Emi ko si le sọ boya otitọ ni tabi rara, Emi si ni mo ni lati dahun fun un, ki ṣe ohun ti elomiiran basọ. Emi ko le da ẹnikẹni lẹjọ. A ko ran mi lati dajọ, ṣugbọn lati waasu iṣẹ-iranṣẹ naa ni.

66 Kiyesi, mo ri àkọ́wò bi ìjọ ṣe ri. Ẹnikan ti n ko ri lo n ba mi sọrọ, a sig be mi duro lori akete kan. Mo si gbọ orin to dùn ju ti mo ti i gbọ ri. Mo si wo ohun bọ wa…ati ọpọ awọn obìnrìn kékèké to wa yíká, ti wọn da bi ọmọ ogun ọdun (mejidinlogun, ogun), gbogbo wọn si ni irun gigun wọn si wa ninu asọ orisirisi, orisirisi, awọn asọ, wọn si n yan ni ibamu pẹlu orin yẹn bi wọn ti le ṣe tó. Wọn si n lọ lati apa osi mi wọn n lọ ni ọna kan, Mo si n wo wọn. Mo si wo o nigbana lati ri ẹni to n ba mi sọ̀rọ̀, emi ko si lee ri ẹnikan.

Lẹyin naa mo gbọ orin "tàka n súfé" to n dun. Nigba ti mo si wo apa ọtun mi, to n bọ wa ni ọna kan bi eyi (Óhún padàbọ̀), awọn ijọ aye lo n bọ yi. Ati awọn kan ninu… ọkọọkan wọn gbe asia wọn lati ibi ti wọn ti wa - awọn ohun to dọ̀tí jù ni wíwò ti mo tii rí rí ni aye mi. Nígbàti ijọ Amẹrika goke wa, o jẹ ohun ìríra to buruju ti mo ti i ri! Baba wa ọrun ni onidajọ mi. Wọn wọ yẹ̀rì pénpé aláwọ̀ọ̀ eèrù (bi okan ninu awọn ọmọbinrin ilé-ọtí) ti ko bo ẹ̀yìn rárá, ni bi, ó mu ohun to da bi tákàdá kékeré aláwọ̀ọ̀ eérú, ati bi ijo o aye, wọn kun ọ̀dà soju, irun kukuru, wọn n mu sìgá, wọn n lọ́ bi wọn ti n yan si orin tàka n súfé yẹn.

Mo si sọ pe, "Ṣe eyi ni ijọ ti ori lẹ ede Amẹrika?"

Ohun naa si sọ pe, "bẹẹ ni."

67 Nigba ti wọn si kọja, wọn ni lati muu lọwọ bi eyi ki wọn si mu tákàdá naa lọwọ lẹyin wọn nigbati wọn kọja lọ.

Mo bẹrẹ si ni sọkun. Mo kan ro pe, "Pelu gbogbo ìla kàkà mi ati ohun gbogbo ti Mo ti ṣe ati ohun gbogbo ti àwa iransẹ Ọlọrun ti jọ ṣe papo…" Ẹyin ara, emi ko mọ bi ẹ ti ṣe gbagbọ nipa awọn ìran yi, ṣugbọn ni ti emi, otitọ ni; a ti fi idi rẹ mulẹ pe otitọ ni, ni gbogbo igba. Nigba ti mo ri yẹn ti mo si mo wipe o sẹlẹ lọwọ, mo fẹrẹ lee dákú. "Kini mo ṣe? Bawo ni mo ṣe kuna? Mo ti duro deede pẹlu Ọrọ naa, Oluwa, Bawo ni n ba ṣe ṣe…?" Mo ro "ki lo de ti Iwọ yoo fi fun mi ni iran laipẹ sẹyin ti o si ri mi nibi?" Mo si wipe, "O dara, ṣe a o dawon lẹjo bi?"

O si wipe, "Awọn eniyan Paulu, pẹlu."

Mo wipe, "Mo waasu Ọrọ kanna ti Paulu waasu." (Awọn onisowo Kristẹni gbe iroyin rẹ̀ jade). Mo si wipe "kilode? Kilode ti yoo ri bayi?" Mo si ri ọ̀gọ̀rọ̀ awọn asẹ́wó yẹn ti wọn n lọ bẹ́ ẹ̀, gbogbo won wọsọ bẹẹ, wọn si pe ijọ omidan Amẹrika. Mo kan n dákúú lọ ni.

68 Nigbana ní tàràtà ni Mo gbọ ojúlówó orin didun yẹn to padàwá, awọn Iyawo kekere kan naa yẹn lo sì tún n bọ̀ lẹẹkan si. Ó wipe, “Eyi ni ohun tó n jade nítòtọ́ ọ́”. Nigba to si kọja lọ, o jẹ bi iru eyi to ti wà lakọkọ, o n rin ni ìbámu si orin Ọrọ Ọlọrun naa, o n yan-án lọ. Nigbati mo si ri, mo duro sibẹ pẹlu ọwọ mejeeji loke ti mo n sọkun bẹ́ yẹn. Nigbati mo jade koru ninu iran naa, mo n duro ni ita ile mi, mo si n wò ìsọda a pápá.

Kini? Ò ni lati jẹ Iyawo kanna, iru kanna, ti a mu jáde lati inu irú èrojà kanna ti Ó jẹ́ ni ibẹrẹ.

Bayi, ka iwe Malaki ori kẹrin ki a si ri ti kò bá yẹ kí á ní iṣẹ-iranṣẹ kan ni opin ọjọ ti yoo yi ọkan awọn ọmọ pada si ti awọn baba, pada si ojúlówó iṣẹ-iranṣẹ pentikosti ni Ọ̀rọ̀ sí Ọ̀rọ́. Ẹyin arakunrin, ibí ni a wà!

Nisinsinyi, o yẹ ki ijọ yii ni ami kan. Ati ami igbẹyin rẹ̀, a ri ni ibi ninu iwe Mimọ… kiyesi, nisinsinyi. Kiyesi awọn irora ibimọ to ga julọ to tii wa ni igba ijọ Laodekia yi. A ti bí í si inu n … Ijọ ti di atunbi.

69 Ki yoo si agbekalẹ miiran. Ẹnikẹni lo mọ pe ni gbogbo igba ti isẹ iransẹ kan ba jade… Ẹ bi awọn o ni ìmọ̀ nípa ìtàn. Lẹyin ti isẹ iransẹ kan ba ti jade lọ, agbekalẹ kan ma n jade lati inu rẹ. Ho, Alexander Campbell, o hun miiran lèyin rẹ, Martin Luther ati ohun gbogbo, wọn maa n di ẹgbẹ-to-fi-eniyan-ṣe-adari ni. Bi ó sì ṣe ma n jẹ isẹ iranṣẹ kan ma n lọ fun bi ọdun mẹta - isọji kan. Eyi si ti n lọ fun bi ọdun mẹẹdogun, kò sì tii si ẹgbẹ-to-fi-eniyan-ṣe-adari kankan to ti ìnu rẹ jade. Kí lò fáá? Iyangbo naa lo gbẹ yin. A wà ní òpin.

Ṣe o rí awọn irora ibimọ? Ṣe o kiyesi ohun to sẹlẹ? Awọn diẹ to sẹ ku lasan la o mu jade. Idi ni yẹn ti mo fi n pariwo, ti mo n ti ra ka, mo n gbiyanju ti mo si n fi gbogbo oju rere eniyan lori ilẹ aye silẹ lati ri oju rere pẹlu Ọlọrun ti mo si n rin ninu Ọrọ Rẹ.

O wa ninu ìrora. Iyẹn ni ohun to sẹlẹ. Yoo bi ọmọ. O gbọdọ yan ohun to fẹ. A ti kọ idajọ si ara ogiri. A ri pe aye ti fẹ parẹ́. Bẹẹ lori. A si ri ijọ; o ti jẹra, o ti fẹ parẹ́. Irora ìbímọ si wa lori gbogbo rẹ - lori aye ati ijọ naa. Aye tuntun kan si wà ti a gbọdọ bi ati Ijọ tuntun lati lọ si bẹ fun ijọba ẹgbẹrun ọdun. A mọ iyẹn.

70 Wo Ọlọrun fun un (Ẹ feti silẹ daradara si eyi nisinsinyi. Mo n wá si ìparí) àmì rẹ to gbẹyin, isẹ iransẹ rẹ to kẹyin, àmí rẹ to gbẹyin. Ami rẹ to gbẹyin nipe o ni lati pada si ipo to wa ni ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Aye, ijọ naa… wo bi ó ti ri ni ibẹrẹ, gbogbo ọdun sẹyin - lati igba Malaki titi di igba Jesu. Wo lati awọn ọdun yi wa, wo gbogbo rẹ látẹ̀yìn wá, pẹlu ìdibàjẹ́ to wọ inu rẹ. Wo ile aye, bi o ti ri ni igba kọkan - bi igba ọjọ Noah, ati síwájú. O ni lati jẹ irú à fi wé kanna, a si ri iyẹn. “Gẹgẹ bi o ti ri nigba a aye Noah” ari awọn nkan wọnyi ti wọn n sarajọ ni ọna kan naa.

71 Nigbana a ni ami kan to gbẹyin.

Ninu iwe Luku ori kẹtadinlogun, ẹsẹ keji din lọgbọn, Jesu wipe, “Gẹgẹ bi o ti ri ni awọn ọjọ Sódómù, bẹ ni yoo ri ni ìpadàbọ̀ ọmọ eniyan.” Nitori, “Bi o ṣe ri ni Sódómù.” Ẹ ò ri bí?

Nisinsinyi, Jesu ka Bibeli kanna, Gẹnẹsisi ti a n ka. Bayi feti silẹ dáradára, ma pàdánù rẹ̀! Bibeli kanna ti a nka, ni Jesu ka. O si sọ fun Ijọ Rẹ, “Ẹ bojú wẹ̀yìn ki ẹ si sakiyesi nigbati awọn ọjọ Sódómù ba pada wa Lẹẹkan si.” Awọn ẹmi ìdìbàjẹ́, awọn eniyan ti wọn ti n ju ìṣẹ̀dá nù… Ẹ wo ibaṣepọ akọ si akọ tabi ti abo si abo bi o ti ṣe n gbilẹ si ni gbogbo aye loni. Ninu iwe iroyin ni aipẹ yi… O nilati wa si ọ́físì mi ki o si ka awọn lẹ́tà lati ọdọ awọn iya fun awọn ọdọmọkunrin wọn. Ibalopọ akọ si akọ abo si abo si n gbile si, Mo ro pe ida ọgun tabi ọgbọn ni Kalifornia nikan ni ọdun to kọja. Ọpọlọpọ awọn to n ṣe jọba gan papa ni wọn ti fi idi rẹ mulẹ pe wọn n ṣe ibalopọ akọ si akọ ati abo si abo. Ẹ yin ti ẹ n ṣe ijọba mọ iyẹn. Ninu awọn iwe igba de igba, Mo ka a. Ati ninu orisirisi awọn nkan to n sẹlẹ, ti iwọ… [Ẹnikan ninu ìjọ jẹ́ isẹ kan ni ìfèdèfọ̀ ati itumọ rẹ.]

72 Ti Mo ba ni oye to tọ nipa iwe mimọ, iyẹn jẹ ohun ti Ọlọrun so pe yoo sẹlẹ gẹlẹ. “Jẹki ẹni to hun fèdè fọ gbadura pẹlu ki o le sọ itumọ rẹ” Otitọ ni yẹn, Mo ti sọ otitọ fun yin, Ọlọrun si wa nibi lati fi idi rẹ mulẹ. Otitọ ni - otitọ ni.

Nisinsinyi wo. Ki ni isẹ iransẹ yẹn ti Jesu sọ? “Gẹgẹ bi oti ri ni awọn ọjọ Sodomu. ”Bayi kiyesi. Ni óku diẹ ki ajo aye awọn Kenferi ni ina - ina naa. Bayi, gbiyanju lati lo ye rẹ. Ki lo sẹlẹ? Akojọpọ awọn eniyan kan wà, awọn ọmọ ijọ ọ kò gbóná kò tutù, bi i Lọti ati awọn ẹgbẹ rẹ, ni Sodomu. Ọkunrin kan tun wà ti o ti jade kuro ninu rẹ. Ko si nibẹ tẹlẹ. Iyẹn ni Abrahamu, eyi to ni ileri ọmọ to n bọ wa. Ṣe o ye ọ? Sọ wipe, “Amin.” O dara.

Ati nisinsinyi, ki olúborí ìparun naa to de, Ọlọrun fara han fun Abrahamu ni ọpọlọpọ ọna. Ṣugbọn lákókò yi O farahan bi ọkunrin. O jẹ ọkunrin. O si tọ ọ Ọlọrun wá…

Bayi o wipe, “ki i ṣe ọkunrin.” Ọlọrun ninu eniyan ni. Abrahamu pe ni Ẹlohimu! O jẹ ọkunrin.

Sì wó, O joko pẹlu ẹ̀yìn Rẹ to kọ si àgọ́ naa, O si wipe, “Nibo ni Sarah, aya rẹ wa?”

O wipe, “E mi yoo bẹ̀ ọ́ wò ni ìbámu pẹlu igba ti Mo ṣe ileri fun ọ.” Sarah si rẹrin. O si wipe, “Kilode ti Sarah rẹrin?” Ẹ o ri bi?

73 Nisinsinyin iyẹn ni ohun to hun sẹlẹ ni ọjọ yẹn. Lati fi àmì to gbẹyin ti Abrahamu ri han … awọn ti ayanfẹ jade, kuro ni Sodomu. Bayi má ṣe padanu-un owe yi ninu ohun kohun ti o ba ṣe. akojọpọ ti a ti fa jade, ti ko si ni Sodomu ti ko sini sodomu rara. Ṣugbọn meji ninu awọn angẹli naa sọkalẹ lọ si Sodomu, nigbati wọn wọn si de bẹ, a ri Lọti, o si ba ni ipo ipada sẹyin, gbogbo wọn lo n ṣe Ibáṣepọ̀ akọ si akọ ati ìbáṣepọ̀ abo si abo ati awọn ìdibàjẹ́; ẹ mọ itan naa. Ṣugbọn okan wa to duro ti Abrahamu, O un ni elohimu. Wọn wàásù ọrọ ni bẹ, wọn un waasu ọrọ naa, wọn un bu ifọju lu wọn - wọn ko si le e ri ẹnu ọna. Iyẹn ni ohun to jẹ loni. Ṣugbọn eyi to wa pẹlu awọn ẹni ti a fa jade ṣe isẹ iyanu kan niwaju Abrahamu lati fi Ẹni ti O jẹ han, o si wa pẹlu Abrahamu.

O wipe, “Kilode ti Sarah rẹrin (lori ọrọ ọmọ bíbí yi)?” Sarah si jade wa lati sọ pe oun ko rẹrin. O wipe, “Ṣugbọn o rẹrin.” Ko ba si ti pa à níbẹ̀ ti ki i ba ṣe abala Abrahamu. Bẹ gẹlẹ ni Ọlọrun yoo ṣe pa wa ti a ki ba ṣe ara Kristi. Anu Kristi lo di wá mụn- oniyemeji ati idibajẹ ninu Ọ̀rọ naa.

74 Ṣugbọn kiyesi. Kiyesi ohun to sẹlẹ. Jesu yipada nisinsinyi. O si wipe, “Gegẹ bi o ti ri ni aye Lọti, bẹ ni yoo ri ni igba-ikẹyin nigbati ọmọ eniyan ba bẹrẹ si ni fi ara rẹ han.” Ẹ o ri bi?

Ọmọ eniyan ni igba gbogbo ninu Bibeli ma un jẹ wolii kan. Kiyesi, O wa ni orukọ ọmọ mẹta awọn orukọ: Ọmọ eniyan, Ọmọ Ọlọrun, Ọmọ Dafidi, kiyesi. O sipe orukọ Rẹ ti ṣe ọmọ eniyan nitoripe eyi ni isẹ ti O ṣe - ti wolii kan, arí ran. O si wipe, “Ni ọjọ bi o ṣe ri ni igba Noah… nigbati ọmọ eniyan bẹrẹ si ni fi ara Rẹ han, iyẹn ni yoo jẹ igba ikẹyin.”

75 Bayi, ẹjẹ ki a ronu fun isẹju kan. Agbaye ko ti ni iranṣe kan tẹlẹ lori gbogbo aye… A ti ni Finni, Sankey, Moody, Knox, Calvin, ati bẹẹbẹẹ lọ, awọn iransẹ ka kiri gbogbo agbaye, si ijọ naa ninu ìrora ibimọ yi. Ṣugbọn a ko ti ni eniyan to un jade lọ pẹlu isẹ iransẹ to wa fun gbogbo orilẹ ede titi di igba yi ti orukọ pari pẹlu h-a-m, A-b-r-a-h-a-m, Abrahamu, eyi ti o jẹ lẹta meje, Abraham jẹ lẹta meje. A ni ọkan loni ti a n pe ni G-r-a-h-a-m, lẹta mẹfa, mẹfa si jẹ onka agbaye, iye ọjọ ti a da aye. Nigba wo ni aye kọkọ ni eniyan si inu rẹ nisinsinyi, to n waasu ninu aye (ninu agbaye) ninu rẹ to n pe awọn eniyan jade, “Ronupiwada! Ronupiwada! Ṣegbe tabi ki o jade kuro ninu rẹ!” titi di igba yi. G-r-a-h-a-m. Wo ohun to n ṣe, o n waasu ọrọ naa, o n bu ifọju lu awọn ti o wa ni ita, o n wipe “Ẹ jade” - iransẹ kan lati ọdọ Ọlọrun. Jesu wipe iyẹn yoo sẹlẹ ni dédé igba ti ọmọ eniyan yoo fi ara Rẹ han. Nisinsinyi ni bo ni iyẹn wa? Níta lọ́hun ninu awọn agbekalẹ ijọ agbaye. Wọn si bẹrẹ si ni korira ọkunrin naa nitori rẹ̀.

76 Sugbọn ranti ẹgbẹ kan wa ti pẹlu ti o jẹ ẹgbẹ ẹni ẹ̀mí, ẹgbẹ Jakọbu naa, kì ì ṣe ẹgbẹ ti Esau; ẹgbẹ Jakọbu kan wa to n reti ọmọ naa ti ko si ni Babiloni yẹn. Wọn si gba iransẹ kan. Sé ó yé ọ? Abraham - A-b-r-a-h-a-m. Wọn si gba iranṣẹ kan ati iransẹ yẹn… Ki ni ohun tó tóbi, ohun to tayọ ti O ṣe lati fihan pe wọn wa ni igba ikẹyin? O mọ èrò to wa ni ọkan Serah. Ati Jesu Ọmọ Ọlọrun naa, to di ẹran ara, ti o n fi han pe Ẹmi Ọlọrun yoo pada sọkalẹ wa si aarin awujọ ẹgbẹ ayanfẹ kekere yẹn ni igba ikẹyin yoo si fi Ara Rẹ han ni ọna kan naa.

Awọn irora ibimọ. Iwọ arakunrin, jọwọ gbiyanju lati lo ye rẹ̀. Gbiyanju gidigidi. Ṣi ọkan rẹ silẹ fun isẹju kan. Wo Kristi Ọlọrun yẹn kanna wa nibiyi lọwọlọ́wọ́. Oun yẹn kanna; O ṣe ileri awọn nkan wọnyi. Ti O ba si ṣe ileri wọn, dajudaju O lagbara lati ṣe wọn. Ẹ jẹ ki a tẹ ori wa ba fun igba diẹ. Mo fẹ ki o kan ro inu jinlẹ.

77 Baba, o wa lọwọ Rẹ bayi. Mo ti ṣe gbogbo ohun ti mo le ṣe. Mo gbadura pe Iwọ yoo ran awọn eniyan naa lọwọ lati lóye. A ti gbin irugbin, da omi naa ti o jẹ ti Ẹmi Mimọ le lori, Oluwa ki O si bu omi rin fun ogo Rẹ. Ti mo ba ti ṣe asiṣe kan, Oluwa, n ko fẹ lati ṣe bẹ. Mo gbadura, Ọlọrun, pe Iwọ yoo sọ itumọ rẹ̀ si ọkan wọn ki wọn ki o le ri ki wọn ki o si le loye rẹ. Ṣe eyi fun wa, Oluwa ni orukọ Jesu ni mo gbadura. Amin.

Ki Oluwa ko bukun fun yin. Mo nifẹ yin. Ọlọrun yi to waasu Ọrọ yi, Ọlọrun yi to ni ojuṣe lori Ọrọ yi - Temi kan ni lati maa sọ Ọ, Oun ní yoo sọ Ọ di àáyè. Ọlọrun yẹn kanna wa nibiyi.

Bayi melo ninu yin ti ẹ wa nita lo ni aìní kan, e na ọwọ yin soke. Ṣe O ṣe ilérí lati ṣe awọn nkan wọnyi ni opin ọjọ? Bayi, ẹ wo mi. Bayi, gẹgẹ bi Peteru ati Johanu ṣe wipe, “Wo wa.” Wo o, o sọ fun un.

Bayi ìwọ wo ibi yí. Bayi, jọwọ máṣe rin kaakiri. Eyi jẹ ohun to…. Mo n gbiyanju pẹlu gbogbo ọkan mi ninu mi, sa a wà ni ìbọ̀wọ̀ ní tòótọ́. Kiyesi, ẹnikọọkan ninu yin jẹ ẹmi, nigbati o ba n rin …. Nítòótọ́ o jẹ ẹnikan, mo si n gbiyanju lati jẹ ki awọn eniyan gbagbọ.

Obinrin kekere kọja o si fi ọwọ kan asọ Rẹ, o si jade lọ O si joko. Jesu sọ ohun ti awọn isoro rẹ jẹ fun, a si mu larada. Nisinsinyi, O si tun ṣe ileri lati ṣe eyi lẹẹkan si, Ọmọ eniyan naa yoo fi ara Rẹ han gẹgẹ bi O ti ṣe ni Sodomu. Aye wà ni ipo yẹn. Ijọ wà ni ipo yẹn. Nisinsinyi, ṣe Ọlọrun ti pa Ọrọ Rẹ mọ bi? Kiyesi bi Ó ba ti ṣe bẹẹ tabi rara. O, a ti ni awọn àmì, fífò sókè, ìfi èdè fọ̀, asọtẹlẹ, ati bẹbẹ lọ, sugbọn, duro; àmì míiran wà. O, a ni ọpọlọpọ awọn àfiwé ẹran ara. Eyi kan jẹ ki awọn eyi to jẹ ojulowo maa tàn ni. A wọn nkan panda lo ma n mu nkan ojulowo tan.

78 Nisinsinyi, ìwo gbadura, ki o si gbagbo. Mo pe ọ nija lati ṣe eyi. Wo o ki o si gba ohun gbogbo ti mo ti sọ fun ọ gbọ. Èyin méló lẹ gba eyi gbọ pe o jẹ otitọ? Dájúdáju, eni tí o jẹ́; ibi tí o wà. Ẹnìkọ̀ọ̀kan níbi, bi mo ti mọ̀ tó jẹ ajeji patapata àyàfi Bill Dauch ati iyawo rẹ̀ ti wọn joko si òhún yẹn gẹgẹ bi mo ṣe mọ̀ tó. Mo ro pe mo mọ oniwasu kekere yi lati orilẹ̀ èdè Germany, to joko sibẹ yẹn, Arakunrin…. Ati awọn eniyan meji si mẹta ti wọn joko sibẹ yẹn. Enikan lẹyin lọhun láàrin awọn eniyan, lẹ̀yìn lọhun. Mo pe ọ nija lati ni igbagbọ pe ohun ti mo ti sọ fun yin jẹ otitọ!

Kí lẹ rò nìpa ìgbà ti Angẹli Oluwa yẹn sọkalẹ wá si ibi odo lọhun ni nkan bi ọdun mẹ́tàlélọ́gbọ̀n sẹyin to si jẹri si nkan yi? Bawo ni mo ṣe mọ, nigbati Oluṣọ-agutan ijọ Onitẹbọmi mi le mi jade kuro ninu ijọ. To wipe, “Iwo n lá àlákálá, Billy.”

Mo wipe, “Ki i ṣe alakala rárá, Ọ̀mọ̀wé Dafidi. Ti o ba jẹ ọna ti o wu ọ niyẹn… tabi o ohun to wu ọ niyẹn, o le kúkú gba iwe idanimọ ọmọ ijọ kuro lọwọ mi.” Mo mọ pe ẹnikan wa nibi kan ti yoo gbaagbo; Ọlọrun ko ni rán isẹ́-iransẹ láí sí ẹni ti yoo gba A. Ò dájú, nigba ti mo tẹ siwaju lati ma gbadura fun awọn alaisan, o jẹ ohun to dara gan. Sugbọn nigba ti mo bẹrẹ si ni sọ otitọ fun yìn, otitọ Ọrọ Ọlọrun, nigbana, ó yàtọ̀.

O yẹ ki ẹ mọ pe gbogbo isẹ iransẹ lo ma n ri bẹ ẹ.

79 Jesu jẹ iyanu nigbati o wọ inu ijọ ti O si n wo awọn alaisan san ati gbogbo rẹ, sugbọn nigba ti O joko lọjọkan ti O si sọ pe “Emi ati Baba mi ọ̀kan ni wa,” Oo, eyi gan lo fa a. “Ti ẹ ko ba jẹ ẹran ara Ọmọ Eniyan ki ẹ si mu ẹjẹ Rẹ, ẹyin ko ni iye Kankan.” Ko salaye rẹ. O fẹ ri ẹni ti yoo duro ti I. Bẹ́ ẹ̀ ni. Kini o ro pe ogunlọgọ èrò to ni awọn dokita ninu ati awọn nkan miiran maa wi, “Ọkunrin yẹn jẹ …. Iwin tó n jẹ eniyan. Jẹ ẹran ara Rẹ ki o si mu ẹjẹ Rẹ!” Ko salaye rẹ, ko salaye rẹ ri. Sugbọn sibẹ Ọrọ Rẹ jẹ Otitọ si awọn apọsteli yẹn. Wọn ko bíkíta bi ko tilẹ ye wọn, wọn gbaagbọ botiwu ko ri. Wọn mọ 'toripe wọn ti ri Isẹ Ọlọrun, wọn si mọ pe bẹẹ lori. O wipe, “Awọn ni wọn n jẹri i Mi.”

80 Obinrin kan wa nibi to joko sibi, o na ọwọ rẹ soke. Bayi, ẹ le pe mi ni alákatakítí ti o ba wu yin sugbọn ọwọn ina yẹn kanna to dari awọn ọmọ Israeli ninu aginjù, o wa lori obìnrin yẹn.

Nisinsinyi ranti, Jesu sọ pe, “Ni igba kan aye ko ni ri Mi mọ, sibẹ ẹyin yoo ri Mi. Mo wa lati ọdọ Ọlọrun; Mo n pada sọdọ Ọlọrun.” Lẹyin iku Rẹ, isinku Rẹ, O sọ fun awọn Juu, O wipe, “I …” O jẹ apata yẹn to wa ninu aginju. O jẹ Ọwọn Ina yẹn. “EMI NI ẸNI TO N JẸ EMI NI.” Ta ni EMI NI? Ọwọn Ina yẹn ninu igbo to n jo. Sẹ bẹ lori? O si di ẹran ara O si n gbe laarin wa. O wipe,“Mo wa lati ọdọ Ọlọrun Mo si n pada sọdọ Ọlọrun” - fun lati pada ni aworan Ẹmi Mimọ. O si wa nibi pẹlu wa lo ni. A ya aworan Rẹ pẹlu imọ ijinlẹ. Nibi O ni lati fi idi rẹ mulẹ ju gbogbo aworan ìmọ̀ ijinlẹ lọ, tabi ohunkohun; O wa nibi lati fi idi rẹ mulẹ, nitoripe Oun ni. “Emi Ọmọ Eniyan yoo di afíhàn ni igba yi.” Bayi ibẹ ni O wa; Mo si n wo O bayi. Iwọ sọ pe, “Njẹ o ri I?” Johanu ri I sugbọn awọn iyoku ko ri I.

81 Wo o, lati fi ìdí eyi mulẹ bayi. Obinrin yẹn jẹ ajeji si mi. Emi ko ti ri i tẹlẹ rí ni ayé mi. Sugbọn o ni ohun kan ti o kuna pẹlu ọkan ninu awọn ẹsẹ̀ rẹ to si n gbadura nipa rẹ̀. Eyi jẹ otitọ, arabinrin. O ti ṣe isẹ abẹ lori rẹ ri. Eyi ni ọkọ rẹ to joko lẹgbẹ rẹ. O ko wa lati ibiyi; o wa lati ilu Califonia. Orukọ rẹ ni Rowan. Inu ti o n yọ ọ lẹnu naa ti lọ pẹlu, alagba. O ni isoro inú, njẹ kii ṣe bẹẹ? O dara, gbogbo rẹ ti lọ. Ẹsẹ̀ rẹ ti gba iwosàn.

“Ni ọjọ naa ti Ọmọ eniyan”

Nibiyi, ọkunrin kan wa ti o joko ni apa ẹ́yin. Aláwọ̀ dudu ni, ohun kan n yọ oju rẹ lẹnu. Iru iṣẹ to n ṣe… o n ṣe nkan to jẹ mọ ọkọ̀-ayọkẹlẹ… o n kun ọkọ̀-ayọkẹlẹ, o jẹ ẹni to n kun ọkọ. Otitọ ni. Oju rẹ ti n bajẹ lọ. O ṣẹṣẹ gbagbọ laipẹ ni, njẹ kii ṣe bẹ? Awọn ohun to sajeji ṣẹlẹ si ọ. Orukọ akọkọ rẹ ni Fred. Eyi jẹ otitọ. Orukọ ikẹhin rẹ ni Cannt. Eyi jẹ otitọ. Ṣe o gbagbo bayi? Oju rẹ ko ni yọ ọ lẹnu mọ nigbana. Emi ko ti ri ọkunrin naa ri laye mi.

82 Ọkunrin to wa lẹyin lọhun yẹn, oun ko wa lati ibi pẹlu - o wa lati California. Ẹ̀yin n dùn-un. Arakunrin Owens, orukọ rẹ niyẹn. Jesu Oluwa ti wo ọ san.

Emi ko tii ri ọkunrin yẹn ri laye mi, emi ko mọ ohunkohun nipa rẹ. Mo kan n tẹle Imọlẹ yẹn bo ti n lọ ni. Ti o ba le gbagbo, ohun gbogbo lo ṣeeṣe fun awọn to gbagbo.

Ẹni kekere to joko sibi, o ni ìpá. O wọ awò ojù ati aso kotu alawọ eérú. Fred, Ọlọrun ti wo ọ san ti iwọ ba gba eyi gbọ. Ṣe iwọ yoo gba eyi? Bẹẹ ni. Emi kò ti ríi rí láye mi.

Obinrin to joko si ọ̀hún yẹn ti i ṣe aya Holden. Ko jinna si ọdọ rẹ̀, o ni aisan ni oju. Emi ko mọ obinrin naa ri - emi kò tii ri i rí, sugbọn otitọ ni, kiyesi. Ti o ba le gbagbo.

Ki lo n sọkún fun, arabinrin? Okàn rẹ kò lé lẹ̀, ara rẹ ko tun balẹ̀, oni àrùn ọkàn tó n jẹ́ bronchitis - ṣe o gbagbo pe Ọlọrun yoo wo ọ san bi (o n joko ni opin ijoko lọhun)? Ti o ba le gbagbo pẹlu gbogbo ọkan rẹ,

Jesu Kristi yoo wo ọ san, gbogbo ẹ̀gbọ̀n rìrì yẹn yoo fi ọ silẹ, iwọ ni imọlara pe o ti padà si ipo to dara. Eṣu n parọ́ fun ọ. Ṣe o gba a? Bayi na ọwọ rẹ soke ki o si wipe, “Maa gba a gbọ.” Ó dára; gbogbo rẹ ti pari.

83 Kilode? Ijọ yi n la irora ìbímọ kọjá. Ṣe iwọ ko ni ṣe ìyàn rẹ nisinsinyi ni iwaju Rẹ̀? Mo ti fi Ọrọ naa han yin ni gẹlẹ-ohun ti O sọ pe Oun yoo ṣe. La gbogbo gbọngan yi kọ já, beere lọwọ ẹnikẹni ti O ba ti sẹlẹ si, tabi ti O ti ba sọrọ ri tabi ohunkohun to ba jẹ, ki o si wo bọ̀ya mo ti ri wọn ri, mọ wọn ri tabi ohunkohun nipa wọn. O ro pe eniyan le ṣe eyi bi? O jẹ ohun ti ko ṣeéṣe lati sẹlẹ rárá. Sugbọn ki ni? Ọmọ eniyan naa. “Ọrọ Ọlọrun mu ju ìda oloju meji lọ, ìmọ̀ ẹmi yàtọ̀, awọn asiri ọkan.” Gẹlẹ bi o ti rí nigbati O di ẹran ara nibiyi ni ori ilẹ̀ aye ninu Ọmọ Ọlọrun, bayi a ti fi I han lati ọwọ Ọmọ Ọlọrun gẹgẹ bi O ti wa lati pe Iyawo kan jade lati inu awujọ yẹn.

“Jade kuro ninu rẹ! Ki a ya ọ sọ́tọ̀!” ni Ọlọrun wi. Maṣe fi ọwọ kan ohun aìmọ́ wọn! Ọlọrun yoo si tẹ́wọ́ gbà ọ́. Ṣe o ṣetán lati fi gbogbo aye rẹ fun Ọlọrun? Ti o ba ṣetan, dide duro lori ẹsẹ rẹ ki o si wipe, “Emi yoo gba A nisinsinyi nipa oore-ọfẹ Ọlọrun pẹlu ohun gbogbo to wa ninu mi.

84 Hallelujah! Ẹ yin Ọlọrun! Ṣe iwọ gba A gbo? Ki o kàn na ọwọ rẹ nigbana ki o si gba adura pẹlu mi. Jẹwọ ẹ̀sẹ̀ rẹ. Irora ibimọ - ko rọrun lati ku. Sugbọn ku nisinsinyi! Ku! Jade kuro ninu aigbagbọ rẹ! Jade kuro ninu rẹ! Eyi ni Ọrọ Ọlọrun ti a fi han, gẹgẹ bi o ti ri nigbati Jesu wa si aye; o jẹ Jesu lẹẹkan si láàrìn yìn, ti a ti fi idi Rẹ múlẹ̀.

Abrahamu gba ọmọkunrin kan ni kété (ọmọ ileri naa) lẹyin ti iyẹn sẹlẹ. Jesu si n pada bọ̀! Iyẹn ni Ẹmi Rẹ̀. O ti sun mo ilẹ-aye gan an, O sunmọ pipada bọ to fi ṣetan lati tẹwọ gba ọ ti iwọ ba ṣetan lati gba A. Bayi naa ọwọ rẹ soke ki o si gbadura pẹlu mi.

85 Oluwa Ọlọrun, jẹ ki gbogbo awọn àlúfa di awọn pẹpẹ mú. Jẹki awọn eniyan naa kigbe soke. Jẹ ki Ọwọ́n-Ina ati Ọ̀wọ́n Ikuuku wọ inu awọn eniyan lọ loni ki o si mu ọkan wọn gbọgbẹ́, Oluwa, ki wọn si lóye ifarahan Ọlọrun alàáyè ati alagbara. Ṣe eyi fun wa, Oluwa. Tẹwọ gba wọn. Mo gba adura yi fun ẹni kọọkan wọn ni orukọ Jesu Kristi. Kun ẹnikọọkan wọn pẹlu Ẹmi Mimọ, ti ko tii ni Ẹmi Mimọ. Oluwa, jẹki ìpolongo isọji yi, ipade yi, di ìtújade Ẹmi Mimọ ni ọna to lagbara. Jẹ ki awọn alaisan ko gba imularada, ki awọn afọju riran, ki awọn arọ ko rin. Jẹ ki ìfarahan Ọlọrun alàáyè wa si iwaju awọn eniyan yi, gẹgẹ bi o ti ri ni òsán òní, si jẹ ki awọn eniyan naa gba a. Ni orukọ Jesu Kristi ni mo bere fun eyi.

Ẹ na ọwọ yin soke bayi ki ẹ si yin I ki ẹ si gba ohun ti ẹ ti bèrè fun.

MESSAGE hub online

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu
William Marrion Branham
"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7